Ọrọ agba

ỌPẸRẸKẸTẸ ndagba, iru adamọ mbaje. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

Irohin Yoruba

Akiyesi

POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona.

NO. 107 WEDNESDAY APRIL 29 —TUESDAY MAY 5 1964 KOBỌ MẸTA 3D

ẸGBẸ DOMỌNU TA O'DUA FUN ẸGBẸ ALAAKE

Ẹgbẹ Akintọla di arungun

OLOTU Ipinlẹ Iwọ Orun, Oloye Akintola ni ọjọ iṣegun ti iṣe ọjọ kọkanlelogun ọsu kerin odun yi ninu Ile Igbimo Aṣofin Ipinlẹ Iwo Orun pe, eto mbẹ nisisiyi lati yan awon oṣelu si ipo ajẹlẹ agba igberiko kọọkan.

Alhaji D. S. Adegbenro ti ise olori alatako ninu Ile Igbimo Aṣofin na si tako ofin na.

O ni ijoba NNDP fi omugọ farawe ohun ti awon o h u n ti ipinlẹ alafia miran s y c. O si bere p e ise kini awon minist 'antire e t Ijoba NN P gba n ?

Eg l Afẹnifẹre ati Alaku p ifasiti Naijiria t to idasile Ijoba elẹkuni kan fun Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ninu ọrọ ajumọ fọwọ sọiya s ọ awon akọwe ẹgbẹ mejeji, Ogbẹni Yekini Sanusi (AG) ati Ogbẹni J u d e Emezie (NCNC), nwon ni, awon ẹgbẹ ọbaiyeje oṣelu na nwa onakona ti lati fi le jeki eeku ida ijoba wa lọwọ won.

Awon akẹkọ n a ni, Ẹgbe A k i n t ọ l a ko ni pẹ sọ awon ajẹlẹ ti nwon l a yan na di akọwe Ẹgbẹ NNDP ni ilu ti nwon ba y n won si.

Nwon ni awon ko ri si yiyan a w o n ajẹlẹ wonyi nitoripe inakuna owo ori ti awon me-

(Wo oju ewe kejọ)

OLOYE FANI-KAYODE

OLOYE Rẹmilekun Fani-Kayode, igbakeji babasale egbe Domonu, ti o tun je igbakeji Olotu Ipinle Iwo Orun kede ni Ibadan ni ojo kerinlelogun osu kerin odun yi pe afibi egbe Domonu ba je amugbalegbe fun egbe Olomi (NPC) ni Ipinle Iwo to le ri anfani je".

Ninu oro kan ti o fi se ikede kan ti o jade ni Eko pe ko faramo ibasepo egbe Domonu ati egbe Olomi ni o ti tu perepere asiri ilana egbe re sile latti fa awon alatilehin won le egbe Olomi lowo.

O bere bayi: "Kini idi na ninu aiye yi ti mo fi le tako iru ibasepo be?"

Oloye Fani-Kayode fonnn rekoja ala ninu oro re na pe egbe Domonu ati egbe Olomi ni yio papo se Ijoba Apapo lehin ti nwon ba tu ijoba Balewa ka l'Eko.

O fi kun bayi: O ti egbe Alakuko lati se Ijoba l'Eko lailai"

Oloye Fani-Kayode kolu egbe Alakuko tagbaratagbara pelu imoran pe ki nwon fi on lorun sile lati mojuto awọn aidọgba ti o wa larin egbẹ wọn.

Onirohin wa nipa oṣelu so pe koi ti pe osu m e j i bayi ti Oloye Fani-Kayode fi oju egbẹ Alakuko gun igi.

OLOYE AKINTỌLA

Obinrin mẹta pade iku ninu yara

Obinrin meta ninu awon meje lati inu agbo ile kan ti o lugbadi isele moto ti o kolu ile won ni Aroad Izuogu ni agbegbe Aba ni o ku lesekese.

Awon merin yoku, ara won ni Okun'n kan ti nwon wa ni ese kan aiye-ese kan orun wa ni ile iwosan gbo gbo gboo ni Aba nibiti awon onisegun ti nja fun igbala emi won bayi

Isele nla yi se ni ona Ngwa ni Arondizuwaju ni Aba ni ojo kejilelogun osu kerin odun yi.

Aasa ni awon obinrin na nlo lowo nigbati isele na de ba won lojiji ninu yara.

Irohin fi han wa pe ohun ti o mu ki dereba oko na si oko wa nipe o dede ri ejo kan ti o gun ni iwon ese bata meta abo ni egbere ninu oko na.

Nwon pa ejo na sugbon nwon si da awako na duro ni ago olopa.

Nwon si pe oruko awon Obinrin ti o ku na ni Esther Nnotum, eni odun mejidin ladota, Nwahiri Nwosu, eni ogbon odun, ati Nwanyibu Nwato, eni odun marundinladota.

Oruko awon ti o farapa ni Rebecca Katu, Theresa Ogbo, Ilonwa Maliwe (ti o ni oyun osu mejo sinu) ati Ogbeni Josaih Ukaoma.

IPADE

ẸGBẸ Afẹnifẹre fun ekun Ijebu Remọ yio s e Ipade pataki kan ni ọjọ Abamẹta ti ise ọjọ keji o s u karun odun y ni ilu Ishara ni agogo mẹwa owuro.

Irohin kan ti o jade ni ile ise egbẹ na ni Shagamu ninu ose yi fihan pe ipade na yio larinrin ati pe opọlọpọ ipinnu pataki ni nwon yio se nibe.

Alejo ajọmọgbe fẹwọn jura.

Eni ogunodun ti o tun je aboyun, Falilatu Kadri foju kan ile ejọ giga kan ni Ijebu-Ode lori ẹsun p e o ji ọmọ osu meta, Adesina Afolorunso gbe. Ile ẹjọ si fi si ẹwọn odun mẹta pelu ise asekara.

Teletẹle, agbefọba ti so fun ile ejo pe ni ọjọ kini osu k e j i l a odun ti o koja, Falilatu lo si ile kan nibiti o ti gbe omo osu meta labe iya omo na, Iyaafin Olubola Afoloruneo.

O tun fi kun oro re pe iya ati baba omo na, Isaac ko si ni ile nigbati Falilatu bẹ won wo. Omọ kekere kan ti o je omọ odun mẹsan ti oruko re n j e Adekunle ni awon obi na fi so omo won nigbati nwon jade Falilatu si fi etan gbe omo na kuro lodo eniti nwon fi so omo na.

Nwon mu esun na lo si odo olopa lesekese sugbon lehin ojo meji ti nwon fi wa omo na ni awon olopa to ri omo na pelu Falilatu ti o ti fa gbogbo irun ori re.

Atọlagbe jadi iro Ẹgbẹ NNDP

Ọlọla D. Atọlagbe ọmọ egbẹ Afẹnifẹre ọkan niuu awọn asoju Ekiti ni Ile Igbimọ Aṣofin Iwọ-Orun ti ja iro aruuru ti nwon kọ si inu iwe irohin egbẹ Domonu kan ti o jade lati ọjọ kejidinlogun si ọjọ kerinlelogun osu kerin odun yi labẹ akọle pe "Atọlagbe le fi egbẹ Oloppe silẹ."

Ọlọla D Atọlagbe wa so lehin ti o ti ju iro nla yi tan pe, Ki ọjẹ mimọ fun gbogbo enia pe emi David Atọlagbe ọmọ egbẹ Afẹnifẹre asoju iba Ariwa Iwọ Orun Ekiti ni Ile Asofin Iwọ-orun koti koro, ko si ni kuro ninu egbẹ Afenifẹre Naijiria, b ẹni nko si ni wọ inu egbẹ jeunjeun Domọnu (NNDP) tabi egbẹ miran.

O se alaye pe, kii se nitori pe on korira Oloye S. L. Akintọla tabi nitori ife on si Oloye Obafẹmi Awolọwọ ṣugbọn nitori pe on gba ilana egbẹ Afenifere gbọ.

O tun so siwaju pe odi ọdun 1951 ti on ati Oloye E. A. Babalọla ti wọ inu egbẹ na ni Owọ ni ipade idasile kini egbẹ na ni ilu Owọ, o ni on si ni enikini ti o ko polowo egbẹ na jakejado Ekiti.

O tun so siwaju pe, emi ko le di ọmọ egbẹ Domọnu nitori pe, gbogbo awọn ti o di ọmọ egbẹ na ni ati jijo wa ninu egbẹ Afenifere ki o to di igba rogbodiyan odun 1962 eyiti o fa dida egbẹ na silẹ.

Osi kilọ pe ki Onikọkuko iun iwe irohin egbẹ Domonu tete lo dawo ikọkuko re curo.

Ẹgbẹ Alakuko Ẹgba fake kọri

Eka egbẹ Alakuko Egba ti kesi Dokita Michael Okpara ti ise babasalẹ egbẹ na pe enikeni ninu ọmọ egbẹ ti o ba kọ si ajomọsepọ egbẹ Oloppe ati Alakuk', yio ni ki o yọ oluwarẹ bi daaga.

Eniti o towọbọ i w e ti nwọn kọ si Dokita Okpara na ni Ogneni Saka Salawu ti ise akọwe ikede eyiti ọrọ inu iwe na je abayorisi ipade ti nwọn se ni ọjọ'Ru ti ise ọjọ kejilelogun ọsu kerin odun yi ni Abẹokuta. Nwọn ni, awọn amunifotin oluwa Ariwa Naijiria kan ni nwọn ngbogunti ajumọsepọ NCNC ati AG na ni Abẹlẹ atipe eyi wa fihan gbangba pe awọn wọnyi ganan ni nwọn nda orilẹ ede wa ru.

Siwaju sii, awọn gba babasalẹ ẹgbẹ na, Dskita Okpara ni iyanju pe ki o mase gba awọn arije ninu madaru agba ẹgbẹ na laye lati yi lokan pada kuro ninu ohun ti o ti ni lokan lati se.

Ni ibere ni egbẹ ti tako dida Igbimọ Afunnisọ Abẹokuta Urban District Council Management Committee pada pe ọna miran lati tun fa Egba sẹhin ninu awọn nkan idagbasoke ni nwọn tun se gbe dide.

AGBODEGBA NNDP

Ẹ bẹ NCNC mu wa si iranti awọn enia nipa bi tita Igbimọ Ijoba Ibile na ka ti se ṣẹlẹ ninu odun 1961. nwọn sun awọn Egbẹ lekanna pe ki nwọn mase tun fi aye silẹ fun owo inakuna mọ ni asiko yi.

Ninu afikun ọrọ ti egbẹ na so, nwọn ni Igbimọ Alakoso titun ti o wa lori aga

(Wo oju ewe kejọ)

'GBENRO GBA IDA AṢẸ

ALHAJI D. S. Adegbenro, adele babasalẹ egbẹ Afenifere ti gba agbara ati aṣẹ kikun lati fọwọ si adehun ajọsepọ pelu egbẹ oselukoselu ti o ba nwa ite- waju orilẹede yi.

Nwọn fun ni agbara yi ninu ipade Igbimọ Alabẹ-ṣẹkẹlẹ egbẹ Afenifere ti nwọn se ni Ibadan ni ọjọ kejidinlogun osu kerin odun yi.

Irohin kan ti Igbimọ na gbe jade lehin ipade na ni iye wa pe:

"Lati dekun gbogbo aiṣedede ti o wa ni orilẹede yi bayi, papa, aibale okan, ibaje, aisokan, owu, ati inira ti o wa larin awọn enia orilẹede yi,

"Lati dekun awọn orisirisi aidọgba ati yankanyankan ti awọn nkan ti ko awọn enia orilẹede yi si,

"Ni ireti a t i fi opin si gbogbo ewu ti o wa ninu aisedede yi, ki alafia ati idera si le pada wa, ki ijoba alafia le pada, egbẹ Afenifere setan lati ba egbẹ oselukoselu tabi akojopo enia miran ti o nwa ite siwaju orilẹede yi ni ọna ti egbẹ Afenifere pelu ngba wa ite siwaju orilẹede yi,

"Awa Igbimọ Alabẹṣẹkẹlẹ egbẹ Afenifere jake jado orilẹede yi pa ohun po g b e agbara, imoran ati aṣẹ fun adele babasalẹ egbẹ Afenifere, Alhaji D. S. Adegbenro lati jiroro, ki o si pari adehun, ati ki o si fi ọwọ si iwe adehun lorukọ e g b ẹ Afenifere pelu egbẹ oselu ti o ba nfe ilọsiwaju orilẹede yi ni ọna ti yio je alafia ati idera fun gbogbo enia ati ti

Gbadun Ẹmi ẹ pelu STAR

Ọti Beer to gbamuse!

Alapara Ibadan

Ọrọ Olotu
Gbangba ha dẹkun bi ?

NI ọṣẹ ti o koja, a gbe irohin awọn ẹsun ibajẹ ati aiṣedede ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ti kan ijoba Akintọla ninu Ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ Iwọ Orun jade. O je ihamuje nlanla fun wa lati tun ran awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun, paapa awọn asanwo ori leti iru iwa aiṣedede ti ijoba Akintọla nhu si ewo won. Ko ye ki awọn aṣegita, ajawetu, aponnita, aroko-kura, ọlọmọlanke ati awon bẹẹbẹ lọ ma ṣai mọ iru "iṣẹ atunṣe" ti awọn jẹun-jẹun oselu melo kan ni oogun oju won ṣe.

OHUN ti o dun wa julọ nipe ki iṣe awọn ti o wa lori akaṣọ ni orun inira ati iponju npa, sugbon awọn ti o wa ni isalẹ akaṣọ ni orun iponju ati inira gbe ṣanlẹ bi akowarapa. Ijoba rere kan ha le tẹle ilana "owọ ẹniti ko ni", ni a o ti gba fun ẹniti o ni"? Igbe aiye ha le dara ninu aiye ti ọlọrọ ti npa owo mọkunnu je bi epa? Oba rere gba awọn enia Re la!

ORISIRIṢI ẹsun ni awọn alatako fi kan ijoba ati awọn enia ninula miran sugbon esi ijoba dabi ti alaimọkan ti ori okan re ṣegun re. Ni tiwa, ko si esi ijoba si awọn ẹsun na ti o sunmọ aakaye. A ro wipe awọn ẹsun gbankọgbanko na gba alaye lẹkunrẹrẹ lati odọ ijoba sugbon o dabi ẹnipe awọn fi awọn ẹsun na tafala nitoripe boya "ko si ẹniti o le mu wa"? Awọn adibo nko nigbana ?

ALATAKO fi ẹsun kan pe ẹgbẹ NNDP ti o nṣe ijoba laidibo gba ọkẹ mejilelogbọn ati abọ pọnun £650,000 lowọ ẹgbẹ Alagbaṣe Guinea Construction Company lẹhin ti ijoba ti gbe iṣẹ adoje ọkẹ pọnuu (£2,600,000) fun-ghẹ na dipo ogorin ọkẹ pọnun (£1,800,000) ti ẹgbẹ Alagbaṣe miran bere fun iṣẹ na. Owo tabua – tabua adọta ọkẹ pọnun £1,000,000 ni iyato. Eyi ko tobi to ndan?

EGBE Alatako fi ẹsun kan pe ijoba Akintọla haya ile adaje agba Dokita G. B. A. Coker fun ẹdẹgbaji o din ẹdẹgbẹta pọnun (£2,500) lodun kan fun odun mewa Idahun ijoba ni ọjọ keji nipe adehun £2,235 lodun ni awọn ba adaje Coker ṣe, nwọn si san owo fun odun meji. Apapọ re fun odun meji je £4,470. Alatako ṣọ wipe owo ihaya lori ile na ko ghodọ ju ẹgbẹrin £800 lẹdun lọ.

ALAYE ijoba lori ẹsun yi ghodọ ti awọn onilakaye enia loju lọpọlọpọ nigbati a ba ranti pe ile itẹju alejo mẹta ni ijoba ni fun itẹju awọn alejo ni agbegbe na. Alejo melo ni ijoba ntọju to bẹ lati fi £2,235 awọn asanwo ori haya pẹtẹsi alaja kansoso lodun? Eyi gẹatiọ!

ỌRỌ ile na ya wa lẹnu nigbati a ranti wipe Alaga Igbimọ Iwadi ti Ijoba Apapọ yan ni odun 1962 lati wadi awọn aiṣedede ninu awọn ajọ iṣẹ ijoba meta ni Ipinlẹ Iwọ Orun, Dokita G.B.A. Coker tun ni baale ile na. Abajade Igbimọ Iwadi Coker ko ṣai di ọbẹ bale - banu Bi abajade na ti nbi Ige lo tun nbi Adubi. O ha ṣeṣe ki Dokita Coker ṣai jẹbi aiṣedede bi igbimọ iwadi miran ba tun dide lori awọn ighokegbodo ijoba ? Ẹniti o ba ngbe ile digi ko ghodọ ju okuta.

KO si ẹnikẹni ti o j gbe tabi ṣe ẹsun pe owo osu lodun Alaga ile iṣẹ ifowopamosi National Bank ti di ẹdẹgbarin o le ai ẹdẹgbẹta pọnun £7,500 laika awon owo pẹpẹpẹ miran kun un.

EGBE Alatako tun ta ọfa esun lu Dokita Sanya Onabamiro pe o gba owo ibọlẹ edegbasan pọnun £17,000 lowọ awon onigẹdu lati le pin igbo ijoba fun won, ti o s fi owo na pamọ si ile ifowopamosi kan loruko obinrin kan. Ko to fun Dokita Onabamiro lati ṣe ẹsun yi lasan. A ro wipe Sanya Onabamiro iba gba ipẹnija Olọla Ositẹlu lori igbimo iwadi lori ọrọ na. Tabi o gbagbe lieri Olọti Ositẹlu wipe oh setan lati jẹri niwaju iru Igbimo iwadi bẹ ? Orukọ rere ko ha tan ju wara ati fadaka lọ?

O ha je ohun iyi fun ijoba lati gbọ pe owo ijoba nipase irin iṣẹ ijoba ni awon Alakoso fi nda oko fun ara won? Dokita Onabamiro ṣe eyi sugbon awon enia ti o wa ni Agọ-Iwoye ko ni sai gba ẹsun yi gbọ. Iwe irohin yi gbagbọ pe irin iṣẹ ijoba ni Alakoso Ijoba kan fi da oko ara re silẹ ni Agọ-Iwoye ni ẹkun Ijebu.

IJOBA ko ṣe ẹsun pe ogun pọnun £20 ojojumo ni nwon san fun elere apala kan ti o "polowo" Olotu Ijoba ni akoko ipolowo fun ikania ni odun 1963. A ko mo iye ojọ ti elere apala na 'polowo' Olotu fun A ro wipe owo inakuna ni eyi ise, paapa julọ ni akoko oda owo ni Ipin'ẹ Iwọ Orun ati paapa bi a ba ronu pe oniwemẹwa ko ri iṣẹ akọwe Ijoba se ni ogun pọnun £20 ni osu kan. Elere apala melo ni o nri ogun pọnun ojojumo gba ni Ipinlẹ Iwọ Orun? Kini alaye ijoba lori eyi?

O HA le je otitọ ni ẹsun ẹgbẹ Alatako pe "Alakoso ijoba kokan ninu ijoba Akintọla ni o gba ẹgbẹrun pọnun (£1000) lati ṣe ajọyọ ominira Ripọbiliki ati lati ra oja awin bi ẹdẹgbẹta pọnun (£500) ẹnikọọkan si ijoba Akintọla lorun, ti ẹnikọkan si tun gba odunrun pọnun (£300) lati fi ṣe yọtọmi odun Keresimesi" — gbogbo wonyi ni odun 1963 ?

IJOBA ko ṣe ẹsun na. Alaye Olọla Kotoye fun ijoba nipe ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o ma nda iru aṣa bẹ nigbati ẹgbẹ na ṣe akoso ijoba. Alaye yi ha wulo bi? A ha le sọ wipe nitoripe Aina jale, Ojo gbọdọ jale? Olọla Kotoye kuna ṣa lati ṣe apere iru iwa aiṣedede bẹ ti Ijoba Afẹnifẹre hu. O ha le je wipe ajẹgbodo nwa enia mọra?

A KIGBE titi lodun ti o koja pe igbe "iṣẹ atunṣe eto aje" ti ijoba nke dabi "iṣẹ atunṣe eto aje" apo oselu kọọkan ti o ba le gbe ori okan re ta. Olọla Ositẹlu ko ha ti fa aṣọ ya loju ẹsun bi, ti o si da wa lare?

OKAN wa ko le ṣai gbọgbẹ ni itara bi o ba je wipe nitootọ ni enia kansoso gba ẹdẹgbajọ pọnun (£15,000) laisise fun. Igbimọ Araja-Marketing Board ti ṣe pe awon ko san £15,000 fun ẹnikẹni. Nibo ni £15,800 wọle si?

A RO wipe ijoba ti fi owọ yọbọyọbọ mu awon ẹsun na rekoja ala le. Ahawon na duro te laisi iwenumọ. A ti kesi ijoba Akintọla ni opọlọpọ igba lati gba aṣe tuntun lowọ awọn adibo sugbon awon oselu ti nṣe akoso ijoba bayi taku bi ẹni pe maku ko ni ku mọ lailai. IROHIN YORUBA ko fi igba kan ni ifẹ si iwa jegudu ragudu, ko ni ni ifẹsi titi opin aiye. A re ijoba Akintọla lati to awon adibo lọ nitoripe awon ẹsun ibajẹ ati mọgomọgo wonyi koja etanu iṣẹlu lọ. Igboran san ju ẹbọ lọ.

Alapara: E ku owuro o, Ṣe dada le ji loni o

Olotu: Ọpẹ ni fun Oba adẹda o.

Alapara: E ma ku odun lleya yi.

Olotu: Edumare yio je ki a sopọ re pelu alafia ara,

Alapara: Amin ati amin

Olotu: Mo ma ṣakiyesi pe ẹrẹkẹ re ndan ati ikun re tun gbe pẹ e die o, Alapara.

Alapara: Bẹẹni ata agbọn olukẹte aje d'oran silẹ lo nje bẹẹ, ki ise ti arun o Olotu.

Olotu: Emi paapa ti mọ pe awọn itan agbo lori ireṣi ko koja yin, ninu odun ileya yi.

Alapara: Mo ti je, mo dara si pelu Olotu.

Olotu: Edumare jẹki a sopọ Odun Alapara.

OJO MBỌ, TITI ỌNA ITIRẸ KỌ DARA.

Alapara: Nje ẹ ko ni ba wa kesi Ijoba Ibile Mushin pe ki nwọn ṣe ẹgbaramu lati tun ọna titi Itire de Lawanson ati Mushin de Itire ṣe nitoripe ojo mbọ o. Ti ojo ba si de tan, odo ni titi na nda, atikẹja moto ati awọn-eleṣẹ di iṣẹ bẹẹ awọn enia wonyi ko salai sanwo ori nwọn decde.

Olotu: Laiṣeaniani Ijoba Ibilẹ Mushin ko sai ni re awọn enia Itire l'ẹkun nipa idamu na. toripe ọba ni tilẹ ti nṣe ti awọn janduku ẹgbẹ NNDP wọnyi si?

Olotu: Awon ọlọpa ti beresi gbo-un ti won nisisiyi. Ṣe o mọ pe janduku ko si lọdọ awọn ọlọpa, bi nwọn ti 'ngmu' fin in lasiko ni nwọn ngba ti mọle.

Alapara: E sa bawa ke si ọlọpa ki nwon le bawa mu awon ni amuwa

ALAPARA IBADAN

nṣe abo fun awọn ti ara ba ngni.

Alapara: Ti nwọn ko ba tete ṣe nko?

Olotu: Nigbana ngo kan si won lati tete ṣe e.

Alapara: Mo gba ti yin gbọ pe ẹ o ṣe bẹ ẹ Olotu.

Bawo ni ao ti ṣe ti Awọn ti awọn janduku won i s. ?

Alapara: Bawo ni a o

Olotu: Jẹki a maa wo ara ti awọn ọlọpa yio fi awọn ẹhanna NNDP na da,ki ngto wa bẹ lu won.

Alapara: Gbogbo ibiti nwọn ba ti nṣe iwa janduku won kiri, ni ugo ma a yin si yin leti Olotu,

Olotu: kafi're pade o, Alapara.

OTUTU BURUKU

Ki ija nla na to bẹrẹ

Lọla ni Dick fẹ ba Ogogun ja, sugbon otutu buruku kan nyọ lenu. O-ma ni bori ti oko ba tete gba ara re lowọ re, Oluko re losọ bẹ, se ajosi o.

"Nibi" Oluko re losọ bẹ. Gba Agolo Mentholatum mi, ki ofi die bọ iho imu re, ki otun fi bọ ọna ofun re, ati ayi re. Sa wa-a dan wo?

"Odami loju wipe ma danwo" Dick sọ bẹ, ose beni aje, ofi Mentholatum bọ iho imu, otun fi pa aiya. Ni ijọ keji oji dide pelu ara yiya.

Nigbati Dick de ori okun Ija, oni ifọkan bale lati ja, Oro wipe on ko ni bori, osi bori, Nkan miran ni iba ṣele toba je wipe Dick ko gba amọran Mentholatum.

Kosi ohun ti odara fun Otutu lati fenkanfẹnkẹn ju Mentholatum lo ṣora ki oma ra awọn afijọ Mentholatum. Ri daju wipe obere fun ojulowo Agbayanu Mentholatum ninu agolo bi eleyi, ati ninu igo funfun.

IPARA TO DARA JULỌ
Awọn ti o nṣe ni Mentholatum Company Ltd. (Est. 1889) Slough England.

Egbe Domonu fe jale Ibo

Ogbeni Olu Ayoola

JAKANDE KO NI EJO —Ayoola

OGBENI Olu Ayoola ajihanran agbejoro so fun ile ejo ganran ni Eko ni ojo ketadinlogun osu kerin odun yi pe, Lateef Jakande okan ninu awon merindinlogun ti ile ejo giga Eko ju si ewon pelu Oloye Awolowo ni osu kesan odun ti o koja lori esun iditẹ tati si oju Ijoba ile ejo kotemilorun ti o fi siwaju ejo o si se afi kun pe ejo re yato pupo si ti awon yoku.

O laa kedere pe dandan ni ki idajo adajo Sowemimo kuna lori ejo idite mo ijoba ti o da Jakande lebi si.

Ogbeni Ayoola so siwaju pe ile ejo ganran ko ni ohun miran lati fi dara duro, ju pe ki o da Jakande lejo on sile lo lehin awon alaye pataki takipataki siwaju awon adajo marun na.

Ekini—awon eleri Ijoba meji Anthony Oboh ati Henry Oleari ti fi igbakan wa ninu awon ti nwon fi esun idi ote mo Ijoba kan, ati pe eri awon mejeji ti ko ba ara won mu ti je eri segesege.

Ekeji—owo ti adajo ile ejo kekere fi han pe Jakande san fun awon mejeji yi kii se owo lati inu apo ara re sugbon owo ti egbe Afenifere ni.

Ogbeni Ayoola fi koko ayewo keta siwaju pe eri ti adajo diro mo pe Jakande ye awon kan wo fun ikeko ni Ibadan ko lese ni le ati pe boya ni awon ti nwon yewo na mo pe awon nlo fun ikeko ogun.

Ogbeni Ayoola so lori ejo ti Ayo Akinsanya okan ninu awon ti nwon fi esun kan na pe nwon ko le mu enia fun wipe o je iranlowo lori ohun kan aya fi ti o ba moomo se ohun na ganan.

Lebanon ta awon Musulumi lore

ITAN irepo nla larin orilede Lebanon ati Naijiria so ni ojo Abameta ti ise ojo kerindinlogun osu kerin odun yi nigbati Ijoba orilede Lebanon fi Egba iwe ede larubawa ta orilede Naijiria lore ninu gbogan nla Mapo lati le fi ese ede na rinle si larin awon ile iwe gbogbo ni Ipinle Iwo-Orun.

Alhaji L A Salami ti o gba iwe na fun awon musulumi Ipinle yi lati owo asoju orilede Lebanon ni Naijiria Slaiman Farah fi si iranti awon enia pe, Ijoba Lebanon ti se itore awon iwe nlanla bi eyi fun ile iwe giga Unifasiti Ibadan ninu odun ti o koja.

A soju orilede Lebanon Slaiman Farah so ninu oro re pe on ati Ijoba Lebanon dupe pupo lowo Alakoso eto Eko ati Ijoba Iwo-Orun ti o je ife won lati fi oyaya gba ki ko ede larubawa niuu ile iwe awon Musulumi kakiri Ipinle yi.

Ogbeni Ayo Ajibola Alakoso ni ibi ile ise eto eko ti o se a'aga ni ibi eye na dupe lowo Ijoba Lebanon fun ipa n'anla ti nwon nko nipa idagbasoke eko orilede yi lapapo ati Ipinle Iro-Orun ni pato.

O to iwon egba awon Musulumi lokunrin ati lobi rin ti o wa sibi eye na.

Oko akoyoyo pa olowo re

OJO buruku esu gbomi mu ni o je fun awamoto akoyoyo kan ti oruko re nje Ganiyu Lawal nibiti o ti da okuta ti oko re ko sile ti ohun kan si ba je ni ara oko re sugbon nibiti o ti fe wo ohun ti o baje na ni oko na ba yi le lori, ti o si te pa bamubamu lesekese ni opin osu ti o rekoja ni Eleiyele Ibadan.

Akosile awon olopa fi yeni pe ni kete ti o ti da okuta inu oko na sile ni ohun kan baje ninu oko na sugbon nibiti o ti gbe fe fi oko na ria sehin ni oro ba yiwo.

Owo olopa te "Sango"

Raimi Ajani enit adape re nje "Sango" farahan niwaju adajo agba, Kotu kekere kan ni Ibadan Ogbeni A. Odumosu fun esun mokanla sarai ti ijoba fi kan'an.

"Sango" ni ba'e awon janduku egbe Domonn. Adajo agba ile ejo na ti pase pe ki nwon fi "Sango" si atimole awon olopa titi di ojo kefa osu karun odun yi.

Ninu awon esun ti nwon fi kan ni ile ejo ni ojo kerindinlogun osu kerin odun yi ni pe o ko awon ohun ija oloro lowo, o si se awon enia lese ni orisirisi adugbo kakiri agbegbe Ibadan.

"Sango" so fun adajo pe ohun ko jebi lehin ti o ti farabole gbo awon esun mokanla ti nwon ka we lese ninu apoti ti o gbe duro nlau aso eleje ati awon ogbe ti nwon di ni bi ona mefa lori re.

Nwon fi siwaju ninu awon esun na pe ni ojo kini osu kerin oduu yi, awon olopa mu "Sango" pelu ada lowo re ni ona Eleta Ibadan pelu ero lati pa enia lura ati pe o pa Wahabi Ishola, Adegoke Akano, Abraham Abiola, Adediran Akangi, ati Ezekiel Odeniran lara.

Nwon si fi kun un pe "Sango" ba oko kan je lojo kan na.

Esun na tun fi han pe ni oje kerinla oru keta odun yi, "Sango" tun ko ada ati awon ohun ija oloro miran, o si pa awon enia mera mlran lara ni opopo 'Labiran, Ibadan. Awon ti o ta jamba fun ni Karimu Olayanju, Busari Olanbiwonnu, Sanni Adeniran, Gbadamosi Ajao, Adegboyega Adediran, ati Raji Akanni.

Ko si agbejoro kan ti o duro fun ni ile ejo ni ojo na.

EGBA TAKO ASE IJOBA

AWON ijoye pelu ogunlogo awon enia ilu Owu ni Abeokuta ti lodi si ase ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria nipa gbigba agbara oye jije lowo Oba Salami Ajibola Gbadela keji. Olowu ti Owu ti nwon si gbe agbara na fun Igbimo oye jije agbegbe Egba.

Ikede gbigba agbara na jade ninu iwe ikede Ijoba ori kokandinlogorun ti ojo kesan osu kerin odun yi, ti o jade ni Ibadan.

Ijoba ko se alaye iru ohun ti o mu won se ofin na sugbon ise ofin na ko sai je nipo kiko ti Oba na ko lati gba oye ori Alhaji D.S Adegbenro, adele babasale egbe Afenifere Naijiria ti o tun je Ekerin awon Egba.

ALHADJI ADEGBENRO

'Gbenro gba agbara

Ni ojo Aje ti ise ogunjo osu kerin odun yi ni Ijoba Ipinle Iwo-Orun Naijiria fi ipo olori alatako fun Alhaji Dauda Soroye Adegbenro, asiwaju egbe Afenifere ninu ile igbimo aso fin Ipinle yi.

Ninu ikeke ti o jade ninu ile Igbimo Asofin Ipinle yi, Oloye Akintola, asiwaju egbe Domonu (NNDP), Olotu Ipinle Iwo-Orun sope gbogbo ohun ti o ba je mo iyi Olori Alatako ni awon yi o gbe fun patapata.

Oloye Akintola sope ipo na ye lati gbe fun un ni toripe ipa ti Olori Alatako nko ninu Ijoba ki ise ohun kekere.

Ninu esi tire, Alhaji Adegbenro sope teletele ni eyi ti wa ninu eto egbe Afenifere lati bu iyi fun Olori Alatako, a si fi kun pe asa Ijoba ni eyi tele.

O tun fi igboiya se itokasi pe apara ti o ga ni fun Oloye Akintola lati yan on gegebi Olori Alatako.

O si tun fi kun pe "o da mi loju gbangba pe iru isele ti o gbe mi d ipo yi nbo wa ba Oloye Akintola ni o'a,"

OLOYE AKINTOLA

IDIBO HA MBO LAIPE BI ?

O ti bere si ni tan kakiri Ipinle yi pe opolopo awon omo egbe Domonu (NNDP) ti o wa lori aga Ijoba Iwo Orun bayi ni o ti ni iwe ibo pupo pupo lowo lati le fi ta jamba ni akoko kakoko ti nwon ba se ikede idibo pajawiri si ile Igbimo Asofin Iwo – Orun

Bi o tile je pe agbowi na ko ja san san, awon omo egbe Domonu ti bere si ni fon nu kiri Igboro pe iwon Iba iwe idibo ti o wa ni ikawo won ti to lati dabaru ibo lakoko to ba de.

Laiko pe egbe Domonu yio dan ara wo lati mo bi awon enia ti wa lehin won to ni agbegbe ariwa Osbogbo Egbe Domonu (NNDP) ti npete Ibo titun fun aye ijoko omo ile Igbimo Asofin kan Ogbeni Ojeniran ti o ti sofo lati igbati o ti ku ni odu 1961.

Oloye Akintola babasale egbe Domonu ti ngba ti ipase oba agbegbe na ro awon ara agbegbe yi lati gbe omo egbe on kan wo le lai ni alatako.

Bi ohun gbogbo ba ri bi egbe Domonu ti ni ero, eleyi yio fun egbe na laye lati fonnu pe awon ni enia lehin ju gbogbo egbe yoku lo

Gbogbo apoti idibo ni nwon ti dapada si odo awon alakoso Ibo ni agbegbe kokan bayi.

Classified Advert

Da Iko Otutu Duro

Ti o ba nwuko tabi o ngmi tipatipa ti o ko si le mi dele tabi sun dada nitori ike-ife tabi amodi inu tabi ikootutu ti o mba e ja Lo ra MENDACO loni ni ile itajaegbogi MENDACO ma a nsise ninu eje ati iho ona ofun lati fo gbogbo kelebe ti o ba di sibe. Nigbana iko re a fuye, wa a si le mi dada wa a si ma sun bi omo-owo wa gba agbara re gan an pada. Bi ko ba je be e, a se ileri lati da owo re pada. Lo ra MENDACO loni lodo onibara re ti o nta oogun.

Lo aye yi fun Ipolowo Oja re April 29, 1964.

CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

Sile kan abo 1 6d fun Ila, oro Marun kan, ati bi oba ti se po si (oro mewa, Ila meji niyen) Jowo ko oro kan kan si nu aye ti owa ni isale yi, ki omu wa, tabi ki o fi ran se si Advertisement Manager Irohin Yoruba, 214 Broad Street P, O, Box 2416 Lagos.

					6
2					3/-
3					4/6
4					6/6
5					7/-
6					9/6
7					10/-
8					12/-

Iye Owo jijade lekan——————Lines at 1/6d————

I enclose ——————for the cost of————insertion

My Name ——————

Address ——————

Signature ——————

A receipt will be posted to you.

'Sango' sa Abiyamo laake

DOKITA Adeboye Olufemi Buckner, oga ile ise alaisan Oshogbo so ni ile ejo kekere ni Ilesha pe nigbati nwon gbe Rosaline David wa ile iwosan fun itoju ni ojo kerin osu kerin odun yi, on ri opolopo ogbe ni ehin owo re, ati ni apakan ese otun re pelu.

Dokita Buckner nso awon oro wonyi fun adajo lori esun ibaje ti nwon fi kan Raimi Ajadi -- 'Sango".

Ni ojo kerin osu kerin odun yi nigbati Oloye Akintola ati igbakeji re, Oloye Fani - Kayode wa si Ilesha ni nwon sope Raimi Ajadi ko lu Rosaline ati Michael Molokun ti o si pa won lara yankanyankan.

Ni ojo kefe osu karun odun yi ni nwon yio to tun ma gbo ejo na.

Otitọ ni yio bori

LATI ỌWỌ —ẸSỌ IKOYI

Ẹma jagun nso, ẹnyin ọmọ Oduduwa
Ẹ maṣe bikita f'ọlọtẹ ẹ maṣe bikita f'eke
Ẹ fi ọdalẹ enia to nọbe saree ara rẹ silẹ
Ọjọ idamu ati abamọ wọn ti wọle tan
Ẹ pada lẹhin ẹgbẹ ọlọtẹ, ẹnyin ti ẹ ba ti ba wọn lọ
Ẹ pada si ẹma ba ba wọn lọ t'owọ ẹgbe
Ẹ pada, ẹ maṣe ba wọn lọ sibi iparun
Ẹ pada, kuro lọna ọrun apadi
Ẹ pada, ki ẹ ma kabamọ lẹhin ọla
Abamọ ko l'ogun, ka kuku maṣe e l'ẹbo

ẸLẸṢẸ YIO JIYA

Ẹ pada, ẹ maṣe lọ ba wọn ku iku eji
Ẹ pada ẹ maṣe lọ ba wọn ku iku ẹrun
Ki sa ṣe ohun gbogbo to ba ndan ni wura
Nkan ko si ri bi a ti nro o
Iwọ sa wo o bi nwọn ti nṣiwere
Ti nwọn nfi rikisi ati ọtẹ pin ara wọn ẹyẹ-ẹyẹ
Nwọn pe eleyi ni ajọ ti lagbaja
Nwọn pe tọhun ni ajọ ti Tẹmẹdo
Nwọn nkakiri ile awọn ọselu loru-loru
Lati bẹ wọn bi ẹni bẹrẹsa-nitori ipo ati owo
Otitọ ni yio bori

ILERI ASAN

Ẹ pada ẹ maṣe ba wọn lọ soko eru
Nitori ikri owo TI NWỌN KO NI MUṢẸ
Sa wo o, awọn to gb'owo lọwọ ukuuku onisunmomi
Nwọn ko ni fi tọ en kọri ḳtu wo, nwọn npuro ni
Imotara-eni-nikan sa ni ero awon
Nwon ko bikita bi ebi pa iwo ati awon omo rẹ ku
Pada lẹhin ologbon ẹwẹ ati Janduku enia
Pada lẹhin odalẹ ki ise ma ba da o pẹlu won
Ẹ maṣe gb gbe orẹ ati olore nyin atijo
Eni yiowu to se iru eyi ota Olorun ni
Otito ni yio bori

O ye, ki a ki awon aklkanju aṣiwaju wa
Ti nwon ko dẹlẹ, ti nwon ko mikan bi ogun ti gbona to
Awon ti a gb'owo onisunmomi fun ti nwon ko
Ti a fi owo nla ati ipo giga ro, ti nwon ko yeṣe ninu Olọpẹ
Alhaji Adegbenro, Alhaji Obisesan, Amofin Bola Ige
Oloye Ajasin, Ogb;ni Bright, Agunbiade Bamiṣe
Iyaalin Ina Nusa ni Ipinlẹ Ariwa
Amofin Akin Olugbade, Ogbẹni Gbọlagunte ati Briggs
Alhaji Masha ati gbogbo ẹni wa nigboro Eko
Oloye Odẹbiyi, Sogbẹin, Lanlẹhin, Babatọla
Otitọ ni yio bori

Mo ki gbogbo enia wa ni Ijebu ati ni Ibadan
Mo ki nyin l'Ekiti ati l'Ogbomọsho
Ẹ ku aroti o, ẹnyin Olọpẹ ni Oṣun
Omọ-Eso ki gbogbo Olọpẹ n'Ipinl: Iwọ-Orun
Mo ki gbogbo ẹny'n iya ati baba wa
Mo ki enyin iyawo, ẹgbon ati aburo
Nse ni ki ẹ duro sinsin l'aiyẹsẹ
Ija na ferẹ tan na, ti iṣẹgun yio jẹ tiwa
Lẹhin onisaru ati ala oriti ni Olọrun sa wa
Edumare yio pin ire rẹpẹtẹ kari gbogbo wa
Otito ni yio bori

Mo ki enyin akikan ju obinr n
Ti enfii igboiya na gbe asia Olọpẹ s'oke
Mo kan sara si eny n agba ati enyin odọ
Ti a npọn l'oju ti a si nfiya je nitori ododo
Ẹ mase foiya, e jeki okan nyin duro
Olọrun l'a fẹhinti: oju ko ni ti wa
Awolọwọ ni ko si nile t'awọn odalẹ nyọ ferẹ
Awo na si ferẹ de na ti o ya won sonu bi agbado
Tiwa ni ijagun-molu, ti odalẹ ni jijin s'ofin
Ofin na ti nwon wa silẹ omọ wọn ni o jin si
Otitọ ni yio bori

Ẹ mase beru awon odalẹ, eni egun
E beru Olorun, ẹ beru olododo enia
Bi aba ni ka beru enia ki ise bi t'awọn eke
Ki ise bi ti awọn odalẹ to nfagbara wa ipo m'aiya kokoko

Ka fagidi jaiye ko tun nkankan se
Otitọ inu ati iwa irẹlẹ lo le mu ni niyi loju awon enia

Eniti onfi ipa ati eru jaiye ki ije pẹ
Olọrun Oduduwa yio ge iranti odalẹ kuro lori ilẹ
Lọla yi gan ni Oluwa yio f'ọ itẹgun wọn
Nwọn yio si damu lọpọlọpọ bi aguntan ti ko loluṣọ
Otitọ ni yio bori

Ẹ mase foiya, ẹjẹ ki won ma gbẹro ibi wọn
Aiseke ki feke ku, odalẹ ni yio ru eru ara rẹ
Ẹ duro sinsin ẹnyin omọ Odua ki ẹ si fohun sokan
Eku ida yio pada sọwọ Olọpẹ laipẹ yi
Awon to ti niiya yio bẹrẹ si joro
Ayo ni yio kẹhin ebi fun gbogbo wa
Jek'a parapo gbogun ti awon odale
K'Olọrun fun wa ni'ṣẹgun lori eniti o fe pa'ni run
Ki oju ti awon t'o fe ko wa ta fun Gambari
Ti nwọn fe sọ Omọ Oduduwa di riboribo
Otitọ ni yio bori

Ẹ gba eyi yewo iponju ki isomọ iya ara
Inu eni't'oti l'aso meji ti ko ni'kan ko le dun
Ranti iye omo tio kọwe ade ti ko ri iṣẹ se
Iregun rere ha da fun awon odale
Ani a ko fe l'agb-, won nfi agbara da orin
Omọ Odua kan ko ni ba won gbe orin na
Enyin omo Oduduwa, e mase tan ara yin je
Enyin agbe, onise owo ati onisowo, e lo f'okan bale
Ẹ ba egbe Afenifere duro pelu ọzito inu owo, ola ati ola yio si je ti gbogbo wa.
Otito ni yio bori.

LAKUREGBE LO

Nigbana ni o wipe mo dupe lowo

DeWitt's
Kidney & Bladder Pills

Nwon ngmu eee-inu ati apo-ito re tun ese dada kiakia nwon ti nle gbogbo ero ti o nfa

LAKUREGBE, IRORA ORIKE-RIKE ARA ATI EKIN-DIDUN RE JADE

Nigbana, ti irora re ti se lo, awon koro egbogi De Witt ni o mu o lokun ati agbara nitori nwon tun eje re se dada. Ra koro egbogi De Witt die nisisiyi ki o si ni ilera ati agbara re pada.

All who want the relief they give

FUN ILERA ATI AGBARA

DeWitt's
KIDNEY & BLADDER PILLS
EGBOGI ATEJESE TI GBOGBO AIYE TI MO

Mọsalasi titun ni Ilu Ẹgba

ẸNU ko gba irohin ni ojo ti awon omọ Abẹokuta ti Mọsalasi titun ti nwon si gba aṣẹ Wuteba lati origun ineerin ọdọ Imale Egba Alake lẹnu lọlọyi eyiti yio gba opolopo musulumi lati ma kirun ojo Jimoh.

Gbogbo awon ilu ti o para po ko Mọsalasi na ni Matogun, Medan, Orudu, Oluwo Orudu Agura ati Olokan pelu i.u Lanbe Koye.

Ohun ti o je iyalẹnu fun awon enia lojo na ni pe gbogbo awon onigbagbo ti o wa ba awon Musulumi se eyẹ ni nwon se aluwa'a ti nwon si ba won kirun.

Lara awon alufa pataki pataki ti o wa lati Abẹokuta ni nwon ti ri Alufa Ajiroba, Salawu Orunshọlu ati Alufa Abaren, Alufa Liadi Orunshọlu ati Alufa Afibonsoro, eniti o fi ibon dabira ti ojo na.

Awon alufa ti o kirun lojo na ni Alufa Badaru Ajisegiri. Alufa Belo ati Alufa Salawu Orudu.

Gbogbo ianmo pa owo po yan Tiamiyu Orunshọlu gegbi akapo Latifu Olalekan si je akọwe.

L hin eyi ni awon janmo Mọsalasi na dupe lowo gbogbo awon enia ti o ba wor se aṣeyẹ papa awon ti won wa lati ona jinjin ki Olorun ma ṣe dun won ni laada rẹ.

OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

Ijẹwọ Igbagbọ Afẹnifẹre

Mo gba eto iselu Afẹnifẹre gbọ.
Mo gba Awolọwọ gbọ pelu.
Eniti o da ẹgbẹ Afẹnifẹre silẹ
Awo ti o je aremọdomọ Oduduwa
Eniti a fi eje iselu bi
Eniti a bi ninu Maria Efunyẹla
Eniti o jiya nitori awa mẹkunnu
Eniti a gbe sinu tubu
O fokan bale s'ogba ẹwọn
Lati ma seto silẹ fun Ijọba idẹra
Nibiti yio ti pada wa se Olotu Ijọba Naijiria.
Mo gba ilana nipa idẹra fun gbogbo enia gbọ.
Mo gba Ẹgbẹ Omọ Oduduwa gbọ
Agbega s'oke owo koko
Irọrun fun awọn agbẹ
Ifokanbale fun awọn osise
Ati idagbasoke ti ko nipẹkun.

J. A. F. OGUNLAYI, IKOLE

Aiṣed

Ara ninu Oluwa, ese ti enia lanu bu baba nla enia, o ye ni; eyi ti ko ni forijin, E yi wipe:

Aisedede wo ni awon baba mi ti won lo jina kuro lọ ṣẹlẹ asan? Ti won si Olorun Oluwa Eleda gbogbo aiye ni o an oro yi si awọn enia ori ile aiye: Ibere mi ni pe: Nje awa ma ko pelu Iru awon enia ti Oluwa bu baba nla re bayi? (Jeremaih 2: 4-5

Ara e gbo esun nla ti Olorun fi kan awa enia ori ile aiye: Nje awa ati idile wa ko pelu bayi? (Jeremaih 2: 7. Emi mu yin wa si ile ogba eso lati je eso re ati ire re; sugbon eyin wo

Irawọ a Ẹda

MARS, ni irawo ti ong se atọk ọmọ ti a bi lakoko ti irawo yi w ni a ṣe atunse aiye (reneed earth) igbo, ẹfọ, igi elẹgo yio gba abbara ey tj oxi jẹ eleso yio se eso. Gbo Olọrun ni a tun da lakoko yi gẹg ti a gbon ni agbẹ. Awọn ọmọ ti a y o ni arisiki ow ati ọpọ ọmọ p ati kanju osiṣẹ, ati pataki a t i on yio si ṣe omoluabi si gbogbo enia idera ara ati ti inu. awon yio ma si gbogbo ohun o ba wa niwaju lati le tete ṣe ti na yanju lasiko, won ko ni akaw,. Apapo awon ko jeki a le ṣe awe dele lori igbes abi lakoko yi je jade, nitoripe igb pupọ awon ki ti ni itelorun bi nv beni awon ki ti ni ife ati duro eyi yio mu ki awon maa yi iṣẹ, ohunkohun pada si gbogbo igba yiyipada lo dara.

Awon ọmọ ti aba bi lakoko yi yio je oninu fufu enia, sugbon lakoko ti irawo Mercury ba wa lode, nwon yio kun fun idunnu ati ayo lori o hun gbogbo, sugbon Venus ati Jupiter ni irawo ti o dara julọ fun won, eyi je wipe ni akoko ti agbara awon irawọ wonyi ba wa lode gbogbo iṣẹ (Eries), yio yo ri si rere. Ti o ba jẹpe (Venus) nikanṣoso ni o wa lode gẹgẹbi irawọ owuro, ni asiko ti a bi ọ, eyi yio fun ọ ni igboiya gidigidi io bẹẹ gẹẹ ti iwo yio fi ṣe nkan ti o le fa idamu ba ọ, sugbon agbara igboiya ati iduro sinsin to je ebun at'orun wa fun won, yio ran won lọwọ lati le bori iṣoro won nikẹhin niteripe a

Asobade Er

fun (May 2

VICTORIA—DIVISION I		
Richmond	v Maldonia 1	
Dandenong	v Box Hill x (2)	
Sand'ham	v Moorband 2	
Oakleigh	v Coburg x (2)	
Austria	v Croatia 1	
Bayswater	v Sunshine 1	
VICTORIA — DIVISION II		
Moone P.	v C'wood x (2)	
Pr. Rangers	v University 2	
South Yara	v Forstree 1	
Brighton	v Libertas 2 (x)	
St. Albans	v Williamstoa 1	
Flinders	v Prahran 2	
VICTORIA—DIVISION III		
Croydon	v Heidelberg x (2)	
S'shine H.	v ICI 1 2	
Rosebud	v Northcote 1	
Essendon	v Moorabbin 2	
Springvale	v Ringwood 1	
Frankston	v Trident 1	

Aiṣedede wo ni awọn baba yin ri lọwọ mi?

Ara ninu Oluwa, ese ti enia ba se ti Ọlorun fi lalu bu baba nla enia, o ye a ronu pe ese nla ni; eyi ti ko ni forijin. Ẹsẹ wura wa t ọse yi wipe:

Aisedede wo ni awon baba yin ri ni owọ mi ti won le jina kuro lodo mi, ti won tẹle asan? Ti won si di enia asan? Ọlorun Olusa Ẹlẹda gbogbo aiye ni o so oro yi si awọ en'a ori ile aiye. Ibere mi ni pe: Nje awa na ko pelu Iru awon enia ti Olorun bu baba nla re bayi? (Jerimaih 2: 4-5

Ara e gbo [illegible] nla ti Olorun fi kan awa enia ori ile aiye: Nje awa ati idile wa ko pelu bayi? (Jeremaih 2: 7. Emi mu yin wa si ile ogba eso lati je eso re ati ire re; sugbon eyin wo inu re; e si ba ile mi je, e si so ogun mi di ohun irira. O ma sto; Nje awa na ko pelu awon obileje ti nha awon ohun ti Ọlorun fi si

Lati Owo Alufa Olu Aiyelabola

kawo ati akoso wa je bayi? Nje awa ko pelu awon ti o nha awon aya ati omo wa je nipa kiko won ni iwa kiwa ati isekuse ati iwa agidi ati orikunkun. Iwa agbere ati iwa aibaji enikeleni je.

Nje awa ra ko yi pelu awon alaiubikita obileje ti won fi iwa se oyo nipa bi ba oruko rere won je nitori owo ati ipo. Nja awa na ko yi pelu awon onigbagbo ti o je pe bi idanwo ba ti de idamu yio gba okan wa, a o mi Olorun ati Oluwa bi mewa ni ekarundo na.

Bi idanwo bi de, opo'opo onigbagbo ni ki aisigbekele ninu Olorun nikanṣoso, sugbon igbekele won yio nwa ninu enia ti nse eleran ara lasan.

Bi idamu ati idanwo ba de opo onigbagbo ni yio tojubo ile baba alawo ati onisegun Onighala won yi yin ti pe mewa lese ese. Nitori won ko ni igbekele kikun ninu Olorun Eleda won eniti o mo ohun gbogbo. Elomiran a tele ma wa Iran-lowo enia kiri laifi Olorun saju Iru awon obileje wonyi ni Olorun so nipi iwon wipe "EMI YIO BA WON JA"

Awon ti won pe ire ni ibi, ti won pe ibi fun awon enia ni ire awon ti won fi okunkun pe imole, ti won si pe imole ni okunkun, awon alaibikita ti won nha aiye je ti wọn ni awon tun se, awon panṣiga ati agbere pupa awon iko Oluwa wipe [illegible] yio ba yin ja Jerimaih [illegible] si ba atomode omo [illegible] ja ni Oluwa wi Kini [illegible] ti fe fi ba aiye je Oluwa wipe awon omo enia se ibi meji (Jerimaih 2, 13) won fi emi [illegible] won si nwa kanga [illegible] fun ara won [illegible] le da omi [illegible].

Onirura ona [illegible] awon enia aiye ode oni ngba wa Ipo ola ati Ipo iyorun ni ona ti ina Olorun ko dun si. Iru eso okan Ire awon alaiwe bi Olorun yi ni pe bi ti enikan ko baje ti enikan ko le dara. Eyi mo ki a ma di ere ti a ko le ru fun ra wa ra omonikeji wa, eyi ma ole ati folefole, onijibiti, alagbawogba, apania odale, kun ori ile aiye loni.

Oluwa npe olukuluku eda alaye si ironupiwada kuro ninu ijbe aiye ese ati iwa kosi eniti o mu mi, ki a ma ranti Eleda gbogbo aiye ti nbe li orun. Ọlorun wipe, bawo li o se wipe emi ki o se alaimo, Emi ko topa Balamu?

Wo ona re ni afonifoji, mo ohunti iwo ti se. Iwo dabi abo Ibakasie ayasẹ ti nsa ni ona re ka (Jeremaih : 26). E ronu e piwada: Ijo Ọlorun ku si dede.

Ẹgbẹ ọdọ Ọlọpẹ ni Okitipupa

LAIKOPẸ yi ni ogunlogo awọn ọdọ [illegible] Okitipupa ko ara wọn jọ ninu ipade kan [illegible] Ode-Irele labẹ alaga Oloye Akarigba ti Oke-Irele. Afẹnifẹre ẹka ti aghegoe na

Ki awọn omọ ẹgbẹ na to kọ ara sijọ fun ipade, nwọn kọ lọ ki Ọba Adetokunbọwa Olofun ti Ode Irele. Ọn na si gba wọn towotẹṣẹ ṣugbọn o rọ wọn ki nwọn ṣe ghfara fun jagidijagan oselu.

Bi nwọn ti mba ipade na lọ ni nwon tun gbe oruko tuntun kan eyiti yio pa gbogbo odo Ẹkun Okitipupa po sinu ẹgbẹ na ni ojo iwaju ijo nwon si fun ẹgbẹ tuntun na ni "Okitipupa Divisional Confederation of Action Group Youth's Association."

Nwon sifi ohun sekan fi ilu Irele ṣe ori ibiti nwon yio ti ma a ṣe ipade titi nwon yio fi da ẹka ẹgbẹ na sile ni gbogbo agbegbe na ki nwon to gbe orile ẹgbẹ na lo si Okitipupa.

Awon omo ẹgbẹ na ṣe ipinnu pe awon ni igbẹkẹle kikun ninu Oloye Ọbafẹmi Awolowo, babasalẹ ẹgbẹ Afenifere, ati ninu adele Babasale Alhaji D. S. Adegbenro. Gbogbo omo ẹgbẹ na si fi ohun sokan wipe awon duro gbọn gbọnin ninu ẹgbẹ na.

Irawọ atọsẹwaiye Ẹda Enia

ARIES — Mar. 21-Apl. 20

MARS, ni irawọ ti ong ṣe atọkun kadara awon ọmọ ti a bi lakoko ti irawọ yi wa lode lakoko yi ni a ṣe atunse aiye (renued earth) gbogbo igi inu igbo, ẹfọ, igi eleso yio gba abbara, won yio rawe, ey ti osi jẹ eleso yio so eso. Gbogbo awon ẹda Ọlorun ni a tun da lakoko yi gẹgẹbi ada (butlas) ti a gbon ni agbẹdẹ. Awọn ọmọ ti aba bi lakoko yi y o ni arisiki owo ati ọpọ ọmọ pẹlu. nwon yio jẹ alakanju oṣiṣẹ, eto pataki a t i oninu mimọ, nwon yio si ṣe omoluwabi si gbogbo enia. Nwon yio n i ilera ara ati ti okan, nwon yio ma ni ọgbona okan si gbogbo ohun ti o ba wa niwaju won ni siṣe lati lati le tete ṣe ti na yanju lasiko, imura siṣiṣẹ siṣe won ko ni akawe. Apapo awon ẹbun rere wonyi ko jẹki a le ṣe afwe delẹ lori igbesi aiye awon ẹniti abi lakoko yi jinjado, nitoripe igbesi aiye won yatọ pupọ nwon ki ṣe ni itẹlorun bi nwon ko ba se siṣẹ bẹni nwon ki ṣe ni ifẹ ati duro lori iṣẹ kan ṣoṣo, eyi yio mu ki awon mua yi iṣẹ, ọrẹ dida, eto lori ohunkohun pada ni gbogbo igba ti nwon ba ri pe yiyipada lo dara.

Awon ọmọ ti aba bi lakoko yi yio jẹ oninu fufu enia, ṣugbon lakoko ti irawo Marcury ba wa lode, nwon yio kun fun idunnu ati ayo lori o h u n gbogbo, ṣugbon Venus ati Jupiter ni irawo ti o dara julọ fun won, eyi jẹ wipe n i akoko t i agbara awon irawọ wonyi ba wa lode gbogbo i ṣ ẹ (Eries), yio yo ri si rere. Ti o ba jẹpe (Venus) nikanṣoṣo ni o wa lode gẹgẹbi irawọ owurọ, ni asiko ti a bi ọ, eyi yio fun ọ ni igboiya gidigidi io bẹẹ gẹẹ ti iwo yio fi ṣe nkan ti o le fa idamu ba ọ, ṣugbon agbara igboiya ati iduro ṣinṣin to jẹ ẹbun at'ọrun wa fun won, yio ran won lọwọ lati le bori iṣoro won nikẹhin nitoripe a bi won lati jagun ni. Nwou yio si rin irin ajo kakiri agbaiye lati mo bi gbogbo nkan ti nlọ si.

IṢẸ SIṢE

Iṣẹ Atorinpọ (Engineer) io jẹ iṣẹ pataki ti yio yori si rere fun awon okunrin ti abi lakoko yi, ṣugbon iṣẹ ti o jẹ mo ina dida tabi nkan to ngbona jo eara fun obinrin.

IGBEYAWO

Ọrọ ifẹ yio tete ya fun awon omo ti aba bi lakoko yi nidi eyi oko tabi iyawo orisirisi yio maa yoju lotun on osi, ṣugbon igbi nla kan yio de ti yio si gba gbogbo awon wonyi danu ki oko tabi iyawo pataki to de. Awon ti a bi lakoko yi mejeji ko dara ki awon fẹ ara won loko tabi ni'yawo, awon oko tabi iyawo to dara fun won ni fifẹ ni awon omo ti a bi lakoko ti (Scopio tabi Sagittarius) ba wa lode.

ILERA

Ko si ibẹru fun ilera nwon, ki ẹ sora fun orun gangan ati otutu gbogbo (wind) ki nwon si ma a sun dede fun isimi ara won nitoripe oṣiṣẹ paraku enia ni nwon, nwon si ni lati simi ki ara won ba le tun ji dide.

AWO

Awo orombo pupa lo dara julọ.

AMI OṢIRERE

Dayamondi (Diamond) lo dara.

ỌJỌ ORI RERE

(Thursday) Alamisi, lo dara julo

Onidan Dabira

OGUNLOGỌ ero ni o wa si ibi ere idan ti Dokita "De-love" ṣe ni gbongan nla ti Ile-iwe Ibadan "Boys High School" ni ogunjo oṣu kerin ọdun yi lati tu owo jọ fun idagbasoke ẹgbẹ "Ma-gba-owo-chin tabi Riba" ti Iwọ-Orun eyiti Ọba Akinyẹle Olubadan ti Ibadan jẹ babasalẹ rẹ.

Oloye A. O Folami oludari kan ni ibi ile iṣẹ "National Motors," Ibadan ni o jẹ alaga nibi ere na Ọgbẹni M. E. Petgrare eni ọdun merinlelogorin ti o jẹ ọga nibi iṣẹ ọkọ oju rin ni o ṣe igbakeji alaga Iyaafin B. O. Fọlami si gbe wọn lẹṣẹ.

Dokita 'De-Love' ṣe orisirisi ere ti o gbadun o si pa awọn "idan" ti o larinrin. Ninu awọn ere idan rẹ ni o ti ka nkan lati inu iwe ti nwọn kọ, ti ko siri soju rara.

O sọ awẹ iwe ti nwọn ti sun ni ina di aṣọ inuju, bisikiti, ati orisirisi nkan miran. Bakanna ni o mu ẹiyẹle jade ninu ina ti njo.

Ki o to mu ere rẹ wa si opin o gba ẹiyẹ lọwọ awọn akọ elere meji miran ti nwọn wa danwo boya o gbọwọ ninu "idan" pipa. Ọwọ eni kini ti o ti gba ẹiyẹ ni Olukọ kan ti on na jẹ onidan Ọgbẹni A. O. Ogunremi ti "Progress Play School" eni kẹj si ni Ọgbẹni Amu.

Irohin ko to afojuba ni ti ere aladun na.

DOKITA *DE*-LOVE

Da Ojisẹ Lohun (2)

SALAMU alẹkun fun gbogbo ẹnyin olugbagbọ ododo. Iwasu mi ọsẹ yi duro lori "DA OJISẸ LOHUN" gẹgebi Ọlọrun tisọ fun Anabi wa Mohammed (S.A.W A) pe ninu Quran mimọ surata li Aakafi 46 aya 31 oko bayi pe:- Ape ẹnyin enia wọ, ẹda akede Ọlọrun lohun, ẹ gbagbọ pẹlu rẹ, yio dari ẹṣẹ yin jinyin, yio gbayin la nibi iya ẹlẹta ero.

Jọwọ iwọ olugbagbọ ododo kiyesi lilo ofin inu aya yi dada dida ojiṣẹ lohun, ni yio mọ fa enia k u r o nibi Iparun, aiye ati ọrun, ohun ti anpe ni, Iṣẹ oku kun, ti o le fa iya Ọlọrun bayen, on ni dida ẹṣẹ si Ọlọrun, eyiti ati gbọ lẹnu ojiṣẹ Ọlọrun, pe a ko gbọdọ ṣe, Irọ, Sina, Oti, Jibiti lilu, toturọ si, pipa ọmọnikeji lara, Ole jija, ọtẹ didi Ijeri eke. Idajọ oro, ẹbọ sis fifi gbogbo awọn iwa eri yi silẹ, Ji ida ojiṣẹ lohun, nigba i o kede, wọ, tori ti awọn Ojisẹ totọ jẹ, eni ọwọ ti afi amin Ọlorun yan, wọn sijẹ olujadu Iwalaiye eni wa wa, kuro ninu Iparun, aiye ati tọrun.

Jọwọ Iwọ ọlọgbọn, lọdo awọn ojiṣẹ Ọlọrun lohun, on ni sjiẹ ifẹ Ọlọrun de oju iku, aii ki oko rira gbogbo iwa ọrun, ati iwa aitọ, gegebi ọdaju, ika, ailanu agidi okan, wọbia, oju kokoro, dupẹ fun ẹnu ipin ti opin o, siju wo eniti koto o, wiwọ ti ti onwo eniti ọ saju rẹ iwọ jẹkj o'lo ba ọ.

Ọrọ Ọlọrun, onni o si fa ọ kuro ninu iya ẹlẹta-ero, aiye ati tọrun, Ostiun sọ di eni idariji niwaju Ọlọrun, aya yi fi han wa pe, dida ojiṣẹ lohun se pataki, fun ọnikọni ninu enia tabi dijanmu, tofẹ alijanna

Isẹ si silẹ

A nfẹ asoju ni Eko ati agbegbe rẹ lati ma a ta Iwe Itumọ ala Josefu ati Turari egun Aja Kowe si. SHOYINKA 1, Isiba Street (Odo Eran) c/o Postal Agent Itirẹ via Yaba

Da Ikọ Otutu Duro

Ti o ba nwukọ tabi o ngmi ipatipa ti o ko si le mi dele tabi sun dada nitori ikọ-ife tabi amodi ima tabi ikọ-otutu ti o mba e ja. Lọ ra MENDACO loni ni ile itaja-egbogi MENDACO ma a nsisẹ nmu rẹ ati iho ona ofun lati fọ gbogbo k lẹbẹ ti o ba di silẹ. Nigbana ikọ rẹ a fuyẹ. wa a si le mi dada wa a si ma sun bi omo-owo wa gba agbara rẹ gun an pada. Bi ko ba jẹ bẹ ẹ, a se ileri lati da owo rẹ pada. Lọ ra MENDACO loni lọdọ onibara rẹ ti o nta ogun.

Asobade Ere Bolu

fun (May 2 1964.)

VICTORIA—DIVISION I
Richmond v Makedonia 1
Dandenong v Box Hill x (2)
Sand'ham v Moreland 2
Oakleigh v Coburg x (2)
Austria v Croatia 1
Bayswater v Sunshine 1

VICTORIA—DIVISION II
Moone P. v C'wood x (2)
Pr. Rangers v University 2
South Yara v Ferntree 1
Brighton v Libertas 2 (x)
St. Albans v Williamstou 1
Flinders v Prahran 2

VICTORIA—DIVISION III
Croydon v Heidelberg x (2)
S'shine H. v ICI 1
Rosebud v Northcote 1
Esendon v Moorabbin 2
Springvale v Ringwood 1
Frankston v Trident 1

VICTORIA—DIVISION IV
Ajax v Glenroy 2
Moo'back v Hercules x(2)
Ndle'ton v Nolita 1
Helvetic v Albion 1
Tulla'rine v Chelsea 2
Waverley v Huntingdale 2

SOUTH AUSTRALIA DIV I
Austria v Budapest x (2)
Birkalla v Juventus x (2)
Croatia v Victoria 2
Enfield v Cumberland 2
Hellas v Polonia x (2)

SOUTH AUSTRALIA Div II
Elizabeth v Beograd x (2)
WRE v Malta 2
Lion v Port Adelaide 1
Napoli v Salisbury 1
Orange v Edinburgh 1

A KAN A NI ILẸ NIGERIA — ni ile-iṣẹ ọtọ-kikan kan ti a kọkọ kọ si ilẹ Nigeria, ti o si tobi julọ.

Ó PỌ LORIṢIRIṢI — kò si ohun ti emu fe lo mọtọ fun ti kò ni ri Bedford to bà iṣẹ nā mu.

A KAN A NI B'ẸMIDIJE, a pilẹ kàn a ki ò le ba ilò ti ilẹ Nigeria mu.

MỌ́TÒ BEDFORD

Aja Dudu [illegible]

ON NI MỌTỌ TO NTÀ JULỌ NI ILẸ NIGERIA — mọtọ Bedford lò pọ tò nnà ara ọna ti oriṣi mọtọ yoku lọ.

JU GBOGBO RẸ LỌ—a lè ri irin'ṣẹ Bedford rà tabi tunṣẹ iake-jado ilẹ Nigeria [illegible].

Niger Motors

NIGER MOTORS ni wa ni: Eko, Apapa, Ibadan, Benin City, [illegible], Enugu, Aba, Port Harcourt, Jos, Kaduna, ati Kano.

OLOTU MI ỌWỌN

Iṣẹ Awo ko le parun

INU mi yio dun bi ẹba le gbami laye lati le sọrọ sinu iwe yin oloyinmọmọ ki awọn akotileta arun[illegible]n ọmọ ki o ma gbọ; awọn ti nwọn tori ti nwọn fẹ ko awa Yoruba sinu oko ẹru, awon ọmọ ale ti fi ọwọ osi Juwe ilu wọn, awọn ti won ko jọ baba ti o bi won, ti nwon ko jọ iya, ti won fẹ sọwa di ẹni hẹ niwaju awọn ti nwon ti nwo wa gẹgẹbi digi fun ilọsiwaju ilẹ Naijiria.

Nigbati ọkan ṣoṣo ajanaku ti mi igbo kijikiji—iyọn ni Awolọwọ, nigbati o fi nfi gbogbo agbara rẹ ja fun idagbasoke Ipinlẹ yi, nibo ni Akintọla wa? Ẹkọ ofẹ fun awon ọmọ wa, idasilẹ ile iṣẹ fun awon ti ko riṣẹ ṣe nibo ni Akintọla wa?

Awọn agbẹ nsisẹ nwọn nri owo na ni irọrun, ko si oko ẹru, tabi ẹnyin enia mi ko mọ pe oko ẹru lawa bayi? Ṣebi awon agba ni nwon ma npa Jowe pe ape wa jeun ki yanlẹ', ọran ti Akintọla kọ ọba ẹnikan ja fọwọ fun gbogbo wọn loju.

Awọn ẹgbẹ Alakukọ na wa le ṣe pato wayi, iru ẹda ti Akintola iṣe. Ti ako ba jẹki ẹgbẹ alakukọ ba ẹgbẹ Akintọla, ti nwon npe ni UPP ti o ti wa di abiku nisisiyi ṣe aṣepọ ijọba ni ọdun 1963, a ba da ẹgbẹ Afẹnifẹre lẹbi.

Nkan ti o ṣẹlẹ larin ẹgbẹ mejeji yi ni awọn agba npe ni idajọ ti o ti ọdọ Ọlọrun wa. Ọlọrun ti atijọ ni o npẹ ki o to da ẹjọ, wara ni ti isisiyi nta. Ẹgbẹ Alakukọ ti o gba Akintola silẹ nigbati iji [illegible]lu iba kuu danu bi ẹlub[illegible], ta ni o wa bi ẹgbẹ ti Akintola nbu ẹnu atẹ lu loni.

Ki ẹgbẹ olomi na ma ṣafara, iku ti opa agilinti alawọ a to wa nbọ tori olorogbo ti o [illegible]ara tiẹmitiẹmi.

Emi mọ daju pe pasan ti a fi na iyale, owa laja iyawo. Nkan ti Akintọla ṣe fun ẹgbẹ Alakukọ, yio tun ṣe fun ẹgbẹ Alakukọ, yio tun ṣe fun ẹgbẹ olomi.

Iba fun Oloye Awolọwọ, ẹniti o ti ri nkan ti yio ṣẹlẹ lọjọ iwaju, ki Odua ki oma jẹki a fẹ iru wọn ku, Amin. Bi aiye yi tilẹ koja, tintin ninu ẹrọ mi ki yio koja. Ti oba ṣẹṣẹ, a ba ma bọ Awolọwọ bi oriṣa, ẹniti o ti fi han wa bi ọdun kan sẹhin pe nkan wọnyi yio ṣẹlẹ, ti o si ti kilọ fun wa ki ama ba wa lọ tawa fun awon Hausa.

Ọba ti oje ti ilu fi kun ati eyiti oje ti ilu fi tu, awọn mejeji na ni ao ma darukọ. Bi ati ndarukọ Jesu be na ni asi tun ndarukọ Judasi ṣugbọn awa na mọ eyiti o dara nibẹ.

O pẹ ni o ya ni, ki Akintọla mọ pe ao tun ara wa ri l'owe akalamagbo ni ọdọ awọn adibo. Ao wa ma reti nkan ti Akintọla ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ yio ṣọ.

Bi nwọn yio wa sope ki a dibo fun ọmọlangidi ni o, eyiti nwọn ti fi ọwọ ara wọn sọ di abiku, tabi fun ẹgbẹ ọlọwọ adẹtẹ ati ẹsẹ adẹtẹ ni o, ko iti ye mi rara.

Mo dupẹ lọwọ olotu, ẹo si tun ma gbadun mi ni ọsẹ miran.

Emi ni
Adepoju Adegboye Agbakin,
Ilọra—Ọyọ.

Ẹronu

Bi gbogbo wa ba woye dada a o a ri bi gbogbo nkan ti ri labẹ ijọba afipase ti o wa ni ipinlẹ yi labẹ Oloye Akintọla bẹni ori gbogbo nkan wọnyi, isọkan ni ẹgbẹ Dọmọnu nja fun nilẹ Yoruba.

Ẹjẹ ki a wo iṣe ọwọ Akintọla nigbati o wa ni ẹgbẹ Afẹnifẹre o fẹ lati fi orogun fọ ẹgbẹ na, ṣugbọn gẹgẹ bi owe agba ekute ilẹ gbọn titi, ologini a fẹsọ mu, bẹni Awolọwọ fẹsọ mu Akintọla.

Laipẹ ọjọ nkọ? da ẹgbẹ tirẹ silẹ ti ope ni UPP (Useless Peoples' Party) tabi ẹgbẹ Ọmọlangidi kini ẹgbẹ UPP se ki o to di pe ẹniti o bimọ yi fun ra rẹ fi ida ọjọju lu pa, ti otun wa mu ọwọ oji ẹmọ na da ẹgbẹ miran silẹ ti ope ni Dọmọnu?

Ẹgbẹ NNDP kole ṣe ipinlẹ yi ni ore kọbọ rara nitori arọ lo ma nfi ọjọ alẹ han. Ẹ wo arọ UPP ki ẹ si wo gbogbo nkan ti o ṣẹlẹ si awọn Ile Ẹkọ lopin ọdun to kọja yi.

Ẹ wo bi nwọn da olukọ silẹ; ẹwo awọn oniṣẹ Ijọba miran ni ipinlẹ yi nikan sa ni gbogbo nkan ti ndaru. Ẹtun wo awọn ti o jade ni Kọlẹji (Colle e) ti nwon njiya kiri laisi iṣẹ. Ilọsiwaju tabi isọkan wo lo wa ninu eyi?

Siwaju si, nkan ti o ṣẹlẹ si awọn olukọ ati oniṣẹ ijọba ti bẹrẹ si ṣẹlẹ si awọn elere Ipinlẹ yi.

Ijọba afipase yi ko fẹ ki Ọgbẹni Ogunde je iṣẹ ọwọ tirẹ.

A.A. Oyinkoyede
Ibadan.

TANI LE YA WA KURO LẸHIN AWOLỌWỌ?

Tani yio ha ya wa kuro ninu ẹgbẹ Awolọwọ? Akintọla ni bi? Tabi Fani? Tabi Balewa? Tabi Amọdu? k'a ma ri.

Olotu, inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi l'aye lati ba gbogbo awọn ti o ni ifẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun sọrọ diẹ ati lati fi han fun awọn ọdalẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun pe opin wọn ku si dẹdẹ, ti gbangba yio d'ẹkun, ti kedere yio bẹ wo. Ijọba UPP wọlẹ, ijọba ẹgbẹ 'Digbolugi' tun gba po fun, eyiti ọjọ iku rẹ de tan.

Iṣubu ti 'Digbolugi' yi yio pọ jọjọ; aiye yio gb[illegible], ẹrun yio si mọ. Akintọla di ere fun awọn elegun, eyiti o si wu u ni ifi bo ori ninu awọn ere na. Igba gbogbo n awọn aṣ'waju ẹgbẹ NNDP nba Ẹlẹda ro ẹjọ pe bi o ti da wọn ko tẹ wọn l'ọrun; nitorina ni nwon ṣe gba owo lati cdi keji lati fi bẹ awọn agbẹgita.

Ere akọkọ ti awwn ẹlẹgiri kọ gbe wọ ni ti Jọsi, nigbati ẹṣu wọ inu wọn, ti ọdalẹ kọ ẹhin si olore rẹ.

Ere keji ni ti UPP ti nwọn gbe jade, ti gbogbo aiye nsa fun u. Ere yi buru ju ti isaju lọ, tobẹ ti ere na ko tun ni ṣe m[illegible] jade mọ lailai.

Ere kẹta ni ti 'Digbolugi' ti nwọn npe ni NNDP. Ere na buru ju ti iṣaju mejeji lọ, tobẹ ti gbogbo ẹgbẹ oṣelu ti nbẹ ni Naijiria nkigbe soke, ti uwon si lodi si ẹgbẹ oselu ti iṣe ti Ipinlẹ kansoṣo, ẹgbẹ yi nlo agbara bi ẹniti ọti npa. Bi aparo ti o saba lori ẹyin ti ko si ye, bẹni igbẹhin awọn ti nfi agba ra jọba laiṣe pẹlu ifẹ awọn adibo yio ri.

Awọn [illegible]ẹ yi ti jogun irọ Baba wọn, nitoripe [illegible] ni Baba won, Nibiti ko si ẹgbẹ wọn ni nwọn mọ pe o wa. A! irọ 'Digbolugi' ma pọ o.

Gbogbo ẹnyin adibo, ẹ ṣe giri, ki ẹ si m'ọkan le; nitoripe Oluwa Ọlọrun wa pẹlu yin lati gbe ijọba Awolowo pada fun yin wa, gẹgẹbi Oluwa ti gbe Apoti Ẹri pada fun awon ọmọ Israeli wa nigba lailai.

ALATIṢE.
Komu

Oṣelu ọba fi ara rẹ wọlẹ

Inu mi dun gidigidi fun aye ti ẹ gba mi ninu Iwe 'Irohin Yoruba' ojojumọ nyin lati sọrọ.

Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun osuyi ni ẹniti iṣe adele babaṣalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre, Alhaji Dauda Soroye Adegbenro j'arọ awọn ọba alaye melo kan ti nwọn jẹ ẹgbẹ NNDP, ẹgbẹ Akintọla ti yio di abiku laipẹ ọjọ.

Alhaji D S Adegbenro fi ye awọn enia wipe gẹgẹbi Baba fun awọn enia wọn ati fun Ipinlẹ yi, awọn oba ko gbọdọ l'ẹnu ninu iṣelu. O fi kun un wipe awọn ọba gbọdọ mọ aye wọn nisisiyi pataki julọ, nigbati ipo iṣelu ti daru ni ipinlẹ yi bayi.

Alhaji Adegbenro pa owe bayi wipe, "A ki jẹ aladun meji pọ" Bi o ṣe wipe ọba ni a o ṣe ni ki a ṣe, bi o tun jẹ fun atilẹhin awọn ilu ni ki nwọn ṣe bẹ e. Ko si ọba na ti o le tẹ awọn ara ilu rẹ lọrun, ti yio tun wa tẹ Ijọba ti o daru ni Ipinle yi lọrun.

Alhaji jarọ awọn ọba melo kan pe nwọn nhu iwa ọdalẹ, bọya fun iwa ibajẹ atilẹhin ilu tabi inunibini tabi itanjẹ ni o nmu wọn fọwọ si adehun ifaramọ egbe Akintọla N N D P (ỌLỌWỌ). Alhaji Adegbenro rọ agba nla lu awọn ọba na wipe, nwọn yio jiya lọjọ Iwaju, atipe awọn yio si ma fi oju ẹgbẹ N N D P wo iru awọn oba bẹ.

O wa to asiko nisisiyi fun awọn oba alaiye lati wokanse ki won si sinmẹdọ nipa li l'ọwọ ninu oṣelu ti o daru ni ipinle yi bayi.

Mo fẹ ki awọn ọba ranti ọrọ 'Iwe Mimọ' inu Bibeli eyiti o sọ wipe, 'Kiyesi, emi mbọ kankan, ere mi si mbẹ pẹlu mi lati san an fun onikaluku gegeki iṣe re ti ri.

Ẹgbẹ Ọlọpẹ mbọ lati san fun onikaluku awon oba ni Ipinlẹ yi gegebi iṣe won, ati ipin won ninu ẹgbe Ọlọpe niwon odun meji sẹhin.

Mo fe ki awon ọba mọ daju wipe, atijo ni wipe, "Ṣebimotisọtẹlẹ, ẹgbẹ Ọlọpẹ yio kuku tun gba mi pada bi mo tile huwa ọdalẹ nitori ipo ninu Ijọba Akintọla. Irọ gbaa ni eyi, ṣugbọn ki ẹyin ọba ranti wipe, Oni l'ari a ko t'ola Ọjọ mbọ ni Oluwa Ọlọrun awọn ọmọogun wi o!

Emi ni;
Ọnaolapo Ames
ILUA—OKEHO

Gbọn aisan awọ-ara rẹ nu loru ọjọ kan

Egbogi titun ti nwọn ṣẹṣẹ fi ọgbọn ijinlẹ wari bẹrẹ si fi opin si awọn aisan ekuru, rorẹ, lapalapa, ogodo, ekusa ati Isaka-ẹsẹ loojọ—Onşişẹ lọ nigbati o ba sun.

NIXODERM jẹ egbogi apolu pataki olorisi oogun meje ti o jẹ ipara funfun ti o nyara ba awọn aleebu-ara ja bi Ekuru, Rorẹ, Arasisu, Lapalapa, Ogodo, Ela-oloronto, Oowo-imu, awọ-orisisi kokoro jẹrun-jẹrun ati Isakaẹsẹ. NIXODERM nsiṣẹ ni kiakia a si da ara-hihun duro larin iṣẹju meje. O le ri agbayanu iyipada lẹhin ọjọ kiri ti o ba lo o. Ṣa fi pa oju ibiti o ndun o ni awọ-ara ki o to lọ sun. Tiripẹpẹ ni yio dimọ ibẹ gẹgẹbi ibowọ afẹẹri a si ma a ṣiṣẹ nigbati iwọ ba nsun. Nigbati o ba dide ni arọ ọjọ keji, wa ri [illegible] awọ-ara rẹ ti mọkadara, a di akọtun, a jọlọ, a si ṣe mulomulọ. Larin ọjọ diẹ, enia yio ya awọn ọrẹ rẹ si iyipada na. Maṣe jẹki idaamu mu ọ padanu awọn ọrẹ rẹ nipa pe o ni awọ-ara buruku. Lo NIXODERM l'oni, ki o si ri i bi gbajumọ rẹ yio ti tubọ ga si. NIXODERM ntete yara siṣẹ nitoripe o mba awọn oniruru kokoro ti o nda awọ-ara laamu ja, a si pa gbogbo wọn. Ra NIXODERM ni ile-egbogi adugbo rẹ loni. O gbọdọ ni itẹlọrun pẹlu rẹ, bibẹkọ a ti ṣeleri lati da owo rẹ pada.

NIXODERM

Awọn ọmọ Iwo gbọdọ gba ara wọn la

Jọwọ gba mi laye lati kesi awọn ọmọ Iwo lori igbokegbodo Akintọla ati Fani. Gbogbo awa ọmọ Iwo l'ọkunrin, l'obinrin, l'ọmọde ati agba, asiko de lati mura giri. Awọn ọmọ ile igbimọ Asofin wa ti fi ọgbọn ẹwẹ tan wa jẹ, nwon ti ko wa ta fun ẹgbẹ olomi.

Ni ati ọjọ ti gbogbo ilu ti nkigbe wipe awon fi ara mọ ẹgbẹ Ọlọpẹ, emi ko i ti gbọ igbe Iwo rara. Ẹ mase jẹki Ọba ba wa rara. Enia ni Ọba, enia ni awa pẹlu Ni ojọkọjọ, ẹgbẹ Ọlọpẹ yio fi oju rẹ ri mọbọ, Ọba ti nkede fun Ọlọwọ Adẹtẹ. O yẹ ki Oba mọ wipe baba ni on ati wipe iṣẹ akowe ẹgbẹ oselu kọ ni on wa fun. Mo mọ wipe ẹgbẹ Ọlọpẹ ni a fi ara mọ, ṣugbọn ẹ jẹki a so fun Ọba ti nhalẹ mọ wa ati awon ijoye rẹ pe awa ki iṣe onijẹkujẹ.

Ki Akintola ati Fani mo wipe, "Ẹkun le pẹ titi, ṣugbọn ayo nbọ l'owurọ" Bẹ fẹ, bẹ fẹ ẹo ṣa tu ile ka ni ọjọ kan

Mo dupe pupo Olotu.

Emi ni,
'Jide Kehinde,
Oluponna-Iwo

Inu mi dun si N.R.C NYLON

O je nkan ti mo nfe - nisisiyi mo nlo N. R. C. Nylon, igbesi aiye mi si yipada.

O rorun ni fifo
O rorun ni wiwo
Itelorun ni fun gbogbo igba

Awon ami-nla inu N. R. C. Nylon Taffeta nwa bakanna ni titi irisi re mo loto.

Wa ami-ara N. R. C. Nylon.

O ngmu ayo kun!

NIPPON RAYON CO., LTD.
OSAKA, JAPAN Cable Address: "NIPPONRAYON OSAKA"

ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

I L U	OJO 'RU APRIL. 29 (WEDNESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Agege, Ikeja Ikosi, (Epe).
Abeokuta	Lafenwa Obada Oba Kajola Ajegunle
Ibadan	— — — — — — — —
Ijebu	Ikenne Okun-Owa Erunwon Omu Mamu
Ijesha	Ibefun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijesha-Ijebu. Isara Imodi
Ondo Ati Eti Odo	Esa-oke, Ilase, Epe, Iloba, Iperindo, Imuroko, Ikeji.
Egbado	Igbo-Egunre
Ogbomosho	— — — — — — — —
Ekiti	Oko ————
BINI	Oke mesi; Ifaki; Igede; Ikole
Eti Odo	Uromi
Igbajo	————
Iressi	
Badagry	

I L U	OJO 'BO APRIL. 30 (THURSDAY
Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo — — — — — —
Abeokuta	Atan Agbado Ifo Itori Itoku Isabo Odeda
Ibadan	Olode
Ijebu	Aiyepe Sagamu Ita osu Ogere Irolu Itele
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	Oka, Ilara.
Egbado	Alagba, Ilaro
Ogbomosho	
Ekiti	Ilogbo Ishan
BINI	Eke
Eti Odo	
Igbajo	
Iressi	— — — — — — — —
Badagry	— — — — — — — —

ILU OJO ETI	MAY. 1 1964 (FRIDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Obun Eko — — — —
Abeokuta	Ijoko Iberekodo Asu Wasimi —
Ibadan	Ijaiye-orile, Fedegbo, Oyedeji, Egbeda
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishan Isara
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-Odo,
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — — —
Egbado	— — — — — — — —
Ogbomosho	— — — — — — — —
Ekiti	Egosi, Odo-Aiyedun.
BINI	— — — — — — — —
Eti Odo	Kokori
Igbajo	— — — — — — — —
Iressi	Ọbada
Badagry	Ado-Odo Ilogbe-Ale

I L U	OJO ABAMETA MAY. 2 (SATURDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Mushin,
Abeokuta	Otta Abalabi Sodeke Omida Ilawo —
Ibadan	— — — — — — — —
Ijebu	— — — — — — — —
Ijesha	Oshu Itagun Odogbo Idoko Iloko
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — — —
	— — — — — — — —
Egbado	Araromi — — — —
Ogbomosho	Oke Aiyedun
Ekiti	— — — — — — — —
BINI	— — — — — — — —
Eti Odo	Iloro — — — — —
Igbajo	
Iressi	
Badagry	Badagry Town

I L U	OJO AIKU MAY. 3 (SUNDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Agege Ikeja Ebute Ero Ikorodu
Abeokuta	Lafenwa, Oba- Obada, Kajola, Ajegunle,
	— — — — — —
	Ikenne, Okun-owa Erunwon Omu, Mamu, Ibefu Atikori Imushin Ago-woye Ijesha
Ijesha	Esa-Oke Ijebu-Ijesha Ilase Epe Iloba Iperindo Imuroko
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — — —
Egbado	Oko — — — —
Ogbomosho	Oke mesi ifaki Igede Ikole
Ekiti	Uromi
BINI	— — — — — — — —
Eti Odo	— — — — — — — —
Igbajo	
Iressi	
Badagry	

I L U	OJO AJE MAY. 4 (MONDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo.
Abeokuta	Atan, Agbado, Ifo, Itori, Itoku, Isabo
Ibadan	Olode
Ijebu	Aiyepe, Sagamu, Ita-osu, Ogere, Itele, It Iloti
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	Oka, Ilora.
Egbado	Alagba Ilaro — — — —
Ogbomosho	— — — — — — — —
Ekiti	Ilogbo, Ishan.
BINI	Eke
Eti Odo	Kpaksang, Bomadi, Ekeremor, Toniga,
Igbajo	— — — — — — — —
Iressi	
Badagry	Ojo, Ajido, Iworo

ILU	OJO ISEGUN MAY. 5 (TUESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Obun-Eko.
Abeokuta	Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi, Araro
Ibadan	Ijaiye-orile, Fedegbo, Oyedeji, Egbeda
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishan
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-odo
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — — —
Egbado	— — — — — — — —
Ogbomosho	— — — — — — — —
Ekiti	Egosi, Odo-Aiyedun.
BINI	— — — — — — — —
Eti Odo	Kokori — — —
Igbajo	— — — — — — — —
Iressi	Obada
Badagry	Ado-Odo, Ilogbe-Ale

I L U	OJO 'RU MAY. 6 (WEDNESDA)
Eko Ati Agbegbe Re	Mushin
Abeokuta	Otta, Abalabi, Sodeke, Omida, Ilawo.
Ibadan	— — — — — — — —
Ijebu	— — — — — — — —
	Oshu Itagun Odogbo Idoko Ilok
Ijesha	Araromi — — —
Ondo Ati Eti Odo	Oke Aiyedun
Egbado	— — — — — — — —
Ogbomosho	— — — — — — — —
Ekiti	— — — — — —
BINI	Iloro — — — —
Eti Odo	
Igbajo	
Iressi	
Badagry	Badagry Town

Owe Ilẹ Yoruba

1 Eya ara edi gari silẹ baba ewurẹ yoju ki ise eru agutan baba re

2 Oni kẹẹ, ola ijasu, die-die ni ẹsin ku

3 Enia kori bi sun, aja nhanrun

4 Eni lasan pọ bi igbẹ, eni rere won ju oju lọ

5 Ebi ni ko pa imaje lo ni on ko jẹ aya ehi pa Sule o jẹ ọbọ

6 Ewure nwo alaẹata bi ki oku, Awodi iba ku aladie iba yọ

7 Eni, buburu lo ba eni rereje

8 Ebi npa eiye, agbon nro dugbedugbe, agbon ki ijẹ kọ ise onje eiye

9 Enia ti iba se egbe re nika Olurun ki ijẹ ko ni ipa

10 Ewure Ile ko mo odẹ, iba se agbunrin iba gba ofa je dandan

11 Eke mo Ile rẹ o wo, odalẹ mo tirẹ o bi dana

12 Eku-keku ki irun kọ bori Asin, kokoro-ki-kokoro ki irun ko bori ikamodu, egbokegbo ki irun ko bori sfon, Awo ni yio bori gbogbo awon ota re

Alọo, alọ

1 Igi ya ni igbo, owo lu ena sugbon ko pa arena nia mi kan

2 Eru isu kan a je de Ogbomosho

3 A ge lori ge ni idi, oni ori yio se oro ile baba on

4 Apata satai elubo kansoso

5 Patapata, odi oriapeta apara

6 Ani ko sare o sare, ani ko tẹdọ rin o tẹdọ rin, a ni ko gbe ẹsẹ kansoso kuro loju ona, o maigbe on yio subu.

7 Aboyun elesu marun kọ

8 A ngegi ninu igbo, gbegbo ile jan mi titi

9 Oni ki nso mo oke, mo so mo oke, oni ki nso mo isale moso mo isalẹ, nigbati ope ko mo oju mi moo

Itumọ

1 Enyin adie
2 Ona ti a nrin
3 Ebu isu
4 Osupa
5 Patako esin
6 Oko Reluwe
7 Irula
8 Pati ereke enia
9 Ina momamona

Isẹ ọwọ ibilẹ gbayi

OLOYE S L Akintola, olotu Ijoba Iwọ-Orun ti so pe ko si ohun ti o bura ju, bi ọmọbirin ka iwe mẹwa ti Ọmọkunrin ka mẹwa tabi ki nwọn gba oye mọ oye ninu ẹko bi nwọn ba lo-ndin dodo, akara, tabi se momimọnina ta, ti awon ọmọkunrin si afa igbale ti ni i asa igbati nwọn ko ba ri ise akowe se.

Oloye Akintola sọ eyi ni ibi eiyẹ ifi ise owo ibilẹ yi ran ti eka Iwọ Orun egbe awon Obinrin Orilede yi (National Council of Nigeria Women Society Western Nigeria) se ni ojọ kesan osu kẹrin ẹdun yi ni Ibadan.

Oloye Bello, Alakoso eto owo ijọba Iwọ-Orun ni o se alaga ipade na. Iyaafin T S Ogunlesi Iya egbe na ni o saju Oloye Akintola ati enia patakipataki kakiri lata wo orisirisi awọn isẹ ọwọ ile wa ti nwọn mu wa si ibi ifi isẹ ọwọ han na.

Die ninu awon ise owo ti nwọn se afihan re ni awon aso anko ra aso oke, adire, ti nwọn da ni eya aso oyinbo bi gaun, sokoto katakoto ati awọn aso ofi ni agbada nla ti ile Naijiria.

Nwon fi awon ohun ti a fi amo mọ bi Ife, awo nla, ere eranko bi ehoro, fun eso ati awon ohun eso miran lati ile ise alawo lati Ado-Eki, Ikorodu ati Abeokuta han.

Die ninu awon enia pataki pataki ti o wa si ibi eiye afihan na ni, Iyaafin Kofo Ademola, Oloye Oyesina; Ọlọla Adeyink Morgan, adajo agba Ipinle Iwo Orun; Iyaafin Thanni; Iyaafin Ilola Inwa ati Iyaafin Awe.

Ewi gba ibawi

AWON akẹkọ ọmọ ibilẹ Ado-Ekiti ni Unifasiti Ibadan ti ko agbara-gba iwe kan si Ewi Ado-Ekiti, Ọba Aladeṣanmi keji fun pipade ti o lọ pade Oloye S. L. Akintọla ati awọn amugbalẹgbẹ rẹ ni Ikere-Ekiti:

Ninu ikede ti nwọn gbe jade, nwọn so pe "o jẹ ohun ti o se enia lanu ati pẹ nwọn si ni igbagbọ pe eleyi yio jẹ asemo fun Ala yeluwa na, akikanju ati alagbara Ewi ti Ado-Ekiti lati ko ara re ni ijanu nipa fi fi ara re wolẹ lori oro iselu."

Eleyi si tun mu awon omo ibile Ado na ranti asiwaju awon oba ti Ọba Aladesanmi na se lo si Eko lati lo fi edun okan won han ni odo Alhaji Balewa,

James Oyan d'ologbe

DADDY James Oyan deji Awoyemi di ologbe ni ojo kejilelogun osu keji ọdun 1964 ni ilu Iwere-Ile ni Okeho,

James Oyandeyi je eni ọgọta ọdun ki o to di ọjọ iku re. O jẹ olori Ijọ Onitebomi ki o to fi aiye sile. O si je enikan ninu awon ti o kọ da igbagbo sile ni ilu Iwere.

Ninu itan Daddy James Oyandeyi, o ti wa ninu isẹ Ijọba fun odun mejilelogun (22). O wa ni abe ile isẹ igbokegbodo ọkọ. Gbogbo awon oga re ni nwọn si feran rẹ.

Ninu oro ikẹhin ti Oniwasu E. O. Famu agun so nibi iboji re lori igbesi aiye Daddy James Oyandeyi o sọ pe o jẹ olufokansin si Olọrun ati si Jesu Kristi. O si gbadura pe ki Olorun Oga Ogo gba si owo otun re loke orun.

O si tun gbadura fun awon omo iyawo, ati awon enia ti o fi sile pe ki Oluwa dun won ninu, ki o si ma ba won gbe ninu igbesi aiye won.

Bakanna si tun ni Alufa Babarinde tun gbadura. Nwon wa korin ikẹhin fun oku na.

Lẹhin eyi ni Alufa Famuwagun so oro ninu Bibeli pe "Eru fun eru, ati erupe fun erupẹ". O si se ore-ọfẹ ikẹhin fun oku na.

Opolopọ awon omo ati awon omo omo lo gbẹhin re.

Ẹgbẹ Ọlọpẹ yo Olumofin l'ẹgbẹ

Ẹgbẹ Afẹnifẹre agbegbe Akoko ti kesi gbogbo ọmọ ẹgbẹ won ni agbegbe na lati duro gboningbonin laiyẹ ẹsẹ ninu ẹgbẹ na, ki nwọn si mura lati da oju ko ohunkohun ti o wu ki o de. Nwọn rọ awọn ọmọ ẹgbẹ na ki nwọn maṣe gba gbẹrẹ fun ẹgbẹ Dọmọau (NNDP).

Awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ eyi ninu ipade kan ti nwọn ṣe ni Ajowa Akoko ni aipẹ yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ra rọ ninu ipinnu kan ninu ipade na pe, awọn ni igbekele ninu babasalẹ ẹgbe Afẹnifẹre, Oloye, Ọbafẹmi Awolọwọ; adele babasalẹ, Alhaji D. S Adegbenro; ọlọla R. A. Olusanṣiwaju ẹgbẹ na ni agbegbe Akoko ati gbagbọ awon ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Apapo ati ti Iwọ-Orun ti o duro gboningbonin ninu ẹgbẹ na.

Irohin Yoruba

Ẹgbẹ arungun

laipẹ ọjọ Ijoba NNDP kunnu nsan ni o je, "nisisiyi. o fere je gbogbo awon omọ Egbe NNDP ni Ile Asofin ni minista atipe nigbati yiyan awon ajẹlẹ si igberiko kookan yio mu ki gbogbo awon omọ egbe NNDP ninu Ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Iwo Orun di Minista."

"Njẹ nwon da egbe NNDP silẹ nitori enia ni, tabi a da enia nitori egbe NNDP ?" eyi ni ibere awon akẹkọ na.

Siwaju si i, awon akẹkọ na ni, ejọ Ijoba Akintola ni aiko ri ise se awon enia, sibẹsibẹ Ijoba na nsan owo ribiribi fun awon omọ Ile Igbimọ Asofin.

Unifasiti wọ gau ?

AWON ọjọgbọn ẹkọ ni Unifasiti Ifẹ ti o fi isẹ silẹ ti pe igbimọ alakoso ile-ẹkọ na na lẹjọ nitoripe igbimọ na ti lu ofin akoso isẹ ni ile ẹkọ nla na.

Awọn ọjọgbọn na ni Ojogbon *V.* A. Oyenuga, Dokita S A Ainko, Dokita O. L. Odumosu, Dokita A. A. Fayẹmi ati Ogbẹni M.A George.

Dida ti awọn igbimọ Alaṣẹ ile-ẹkọ na da ọjọgbọn Oyenuga duro ni o fa ọgọrọ ifisẹsilẹ awọn olukọ merin na. Nwọn si sọ ninu iwe ifisẹ silẹ won pe ipari ẹdun ile ẹkọ na ni awọn to kuro lẹnu isẹ.

Ile ejọ so nipa oniruru ipẹjọ ti awọn ọjọgbọn mararun na gbe siwnjuru, ni ọjọ Aje ti isẹ ogunjọ osu kẹrin ẹdun yi

Ojogbon Oyenug fẹ gba £567 : 18s; Dokita Aluko fẹ gba £1,183:6s; Dokita Odumosu fẹ gba £1 564:14:4d; Dokita Fayẹmi fẹ gba £1,:94: 18s; ati Ogẹni Ogbẹni George nfe lati gba £786 6s 9d gegẹbi owo osu rẹ lati osu kẹfa titi de osu kẹjọ ẹdun. Gbogbo eyi si je owo itanran ti nwọn fẹ gba lọwọ igbimọ alaṣẹ ile ẹkọ Unifasiti Ifẹ.

Adajọ ile-ẹjọ na,

Dokita S. A. ALUKO

Ọlọla R. A. Doherty fun olupejọ ati olujẹjọ ni ọgbọn ọjọ lati fi ṣe awari ọrọ ejọ wọn

Iyaafin Folake Sholanke, obirin amofin ni o dele fun Oloye Rotimi Williams na fun awọn olupejọ: ti Olove A. M. A. Akinloye si duro fun awọn olujejọ.

Awọn ọjọgbọn na ti se ohun ti nwọn pe ni 'isokuso' Ogbẹni D. K. Olumofin, Alakoso eto Eko wipe awon mbẹbẹ lati pada si ile ẹkọ na

Ninu oro ti nwon fi kolu Ogbẹni Olumofin, awon ọjọgbọn na so pe awon ko le ṣiṣe ninu ile ẹkọ na Unifasiti Ifẹ labẹ Ijoba ti o wa lode nisisiyi. Nwon si pe Ogbẹni Olumofin ni 'ja lati daruko awon ti o mbebe na.

Alakukọ Egba

(Bere lati oju ewe kini)

nisisiyi ko wa ilọsiwaju Egba bikose isubu wọn nitoripe aibadegba omọ egbe NNDP ni awọn igbimọ na ise. Siwaju sii, nwọn ni nigbati NNDP ti i daju pe, awọn ko le ri idi joko ni Abeokuta ni nwọn ba ti agidi bọ. ti nwọn si bẹrẹsi ko awọn channa omọ egbẹ won kakiri ilu lati maa da awọn alatilehin egbe NCNC ati AG laamu; ki nwọn ba le faramọ egbe akotileta NNDP

MEGIDA
MANJE BI IDANU

Fun Otutu Iko Efori Osi. Imu Ofun didun Lakuregbe. Iba Ewo Akodun Iwora. kiakia Lo npa Oju Ogbe Era Ige kan Fun Itowo
MEGIDA Wa Kakiri Sobu. Asi nta ni
MEGIDA COY. Box 882 LAGOS.

Dear Reader!
let us introduce you (and your family!) to the Remarkable Renault-4

• 845cc 32 B.H.P. More than 70 M.P.H.
• Space for a family of five including their luggage.
• Never needs greasing or water.
• Gets over 47 m.p.g.
• Turns in 28ft. circle.
• Independent 4-wheel suspension.
• Child-proof locks on the three rear doors.
• Fully synchromesh gearbox.
• 6-month guarantee, without mileage limitation.
• Price Ex-Lagos £575 •
ASK FOR A DEMONSTRATION NOW AT
LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS, APAPA, EBUTE METTA IBADAN KADUNA, KANO ILOS, ENUGU ONITSHA P.HARCOURT & ABA.
RENAULT 4

NOW—ROLLS-ROYCE 707s ON THE LONDON RUN

Eto irinajo ayarabiasa ti ojojumọ
NISISIYI oko ofurufu titun fi a npe ni Rolls-Royce 707 ti wa fun awon onirin ajo ti o nlo si Londonu ati awon ile Oyinbo. Rolls Royce ti a mo jakejado aiye fun ero tio dara julo li o se ero ti o ngbe oko ofurufu yi fo bi eiye Fun igbadun ati itura nigbati o ba nrin irin ajo ninu oko ofurufu ayara bi asa, kesi Travel Agent re tabi ki o bere ni Nigeria Airways Booking Office ti o wa ni Broad Street, P O Box 136. Lagos (Telephone 24811) ni Bank Road, P. O. Box 11, Kano (Telephone 3891) tabi awon ile ise oko ofurufu ni agbegbe re.
NIGERIA AIRWAYS
NIGERIA'S NATIONAL AIRLINE

Published by the Eastern Post Limited, Elephant House 214 Broad Street, Lagos and printed for them by the African Press Ltd, P. O. Box 78, Ibadan, Editor: E. O. OLOFIN, c/o 98, Shittu Street, Ibadan